# Isọdọmọ Apa Kẹrin

Jeffersonville, Indiana, USA

Ọjọ Kejilelogun, Oṣu Karun, 1960

1 …Si awọn ọrẹ wa ọwọn, inu wa dun lati pada wa sibi lalẹ yii. Ooru mu diẹ, nitorinaa, a o gbiyanju lati ṣekánkán, bi o ba ṣe ṣeeṣe to, a o lọ taara sinu iwaasu naa.

Ṣaaju, a ni awọn ifilọ kan lati ṣe, ati akanṣe ẹbẹ adura kan. Mo ri iwe rẹ gba, ati fun arabinrin to ni eewo ninu ọpọlọ, omiran si wa lati Louisville, ati arakunrin fun Iranṣẹ Ọlọrun kan, baba rẹ si ni aisan ikọlu ọkan. Ọpọlọpọ alaisan ni o si wa ninu aye. Ọpọ ni wọn npe, a si ngbadura fun wọn, pẹlu gbogbo ọkan wa, pe, ki Ọlọrun ran wọn lọwọ.

2 Bi o ti maa nri, ipa ti o pọju lọ ninu iṣẹ iriju iwaasu mi lo ni iṣe pẹlu gbigba adura fun alaisan. Emi si ngbadura fun alaisan sibẹ, sugbọn mo woye wipe, bi a ba le mu Ijọ de ipo kan ti wọn wa ni eto ati ilana to yẹ, ki a lee ṣe iṣẹ. A nilati mu U wa si eto ti o tọ, ki ohun gbogbo wa ni isọkan.

Ohun miran kan wa si ọkan mi ni iṣẹju diẹ sẹyin, o jẹ nipa ọkunrin arugbo, abode ologun kan, ti ibọn ti fẹ ja apa rẹ kan ati ẹsẹ rẹ kan kuro. Oun ko si nibi bayi lati gbọ mi, sugbọn oun jẹ akọni eniyan gidi ti orukọ rẹ njẹ Roy Roberson. O jẹ ọkan ninu awọn alabojuto Ijọ yii ati ọmọluwabi Kristẹni kan. O joko nibẹ yẹn. O si wipe, “Arakunrin Branham, ma ṣe gbagbe Aarẹ wa. O wipe, ”O jẹ ki aanu ṣe mi pupọ“ nigbati o ri i lori mohun-maworan, ti aarẹ sọkalẹ lori ọkọ baluu ti omije nda loju rẹ, ti ẹnu rẹ si wọ sẹgbẹ kan. Ṣe o mọ wipe, wọn jọ wa niwaju ogun yẹn ni.

3 Ko ṣe Pataki, bi iwọ ba lodi simi nipa oṣelu, oun si ni aarẹ wa. Bẹẹni, sa. Nitemi, emi kii ṣe ẹgbẹ oṣelu Demokirati tabi Ripọbilikani; Kristẹni ni mi. Sugbọn mo sọ fun ọ wipe, emi ti ni ọ̀wọ̀ bàm̀bà fun Aarẹ Dwight Eisenhower. Dajudaju, oun ti jẹ eniyan nla kan gẹgẹbi ero temi. Bi o ba fẹ ṣe aarẹ lẹkan si, ti mo si fẹ dibo, emi yoo tun dibo fun un lẹẹkansi. Otitọ niyẹn. Ko ṣe Pataki bi o ba ti di ẹni ọgọrun ọdun, emi iba tun di ibo fun un, nitoripe, mo fẹran rẹ. Jẹ ki a ranti rẹ ninu adura lalẹ yii.

J.J., mo mọ riri ipade to dara, ti iwọ ati Arakunrin Willard ni lọsẹ yii. Bi mo ba ti wọle ba yin nibẹ, ẹ ba ti wipe, “O dara, Arakunrin Branham, ”ẹ wa sọ ohun kan“. Sugbọn o dara bi mo ṣe duro ni ita ti mo si feti si yin, ṣe iyẹn ko dara bẹyẹn? O dara pupọ.

4 Mo ni awọn aye kan ti wọn nilo Olusọ-aguntan, bi iwọ ba fẹ. Bi iwọ ba ti mura silẹ lati lọ ṣe Olusọ-aguntan - bi o ba ti gba ikọni rẹ, ti mo si gbagbọ pe iwọ ti gba a, - mo ni ọkan ni Oregon, awọn kan ni Washington, ati California, ati Arizona, kaakiri. Bi iwọ ba si fẹ ṣe Olusọ-aguntan, ibiti o dara lati bẹrẹ niyi. Awọn ọkan si wa to nkigbe nibi gbogbo, titi de aarin awọn India. Ibikibi ti iwọ ba si fẹ lọ, sa jẹ ki a mọ, nitoripe, emi gbagbọ pe ẹyin ọmọkunrin ti ni idakọro bayi. Bẹẹ ni.

Mo saa nifẹ lati ri wọn ki wọn ṣe iyẹn. Arakunrin Ruddell ti o wa loju Popo yẹn. Mo nlọ ba a ṣe ipade kan lẹyin ọjọ diẹ si. Mo nlọ ṣe isọji kan pẹlu Arakunrin Ruddell. Mo ranti wipe, mo ti maa nti ọmọde naa ka nibi gbogbo, ti mo ngbiyanju lati mu ki o gbaradi ki o si waasu. Oun si tiju pupọ. Yoo wipe, “Emi ko le e sọrọ.” O yẹ ki o gbọ ọ bayi. Wo o, iwọ ko mọ ohun ti iwọ le e ṣe bi o ba gba Ẹmi Mimọ laaye lati tọ ọ. Otitọ niyẹn.

5 Arakunrin Graham Snelling ni Utica ati Arakunrin Junior Jackson nitosi nibi, a ka gbogbo wọn si arabinrin kekeke si ijọ wa. A wa ni isọkan. Awa ko lodi sira ninu awọn ẹkọ wa, ireti wa, ati afọjusun wa. Awọn ẹkọ opomulero ijọ wa jẹ ọkan naa. A duro papọ ninu ohun gbogbo sọkan. Ijọ kan naa ni a jẹ. A si fẹ ni iru wọn kaakiri si. A ni awọn kan ni Afirika, awọn kan ni India, ati kaakiri orilẹ-ede naa. Ibiti a fẹ ki wọn wa niyẹn, ki wọn ma a tan ihin naa ka.

Mo si ri awọn ọdọ wọnyi ti wọn ndagba si, gẹgẹbi Arakunrin J.T. Parnell to wa nibi, ati Arakunrin Willard ati awọn to ku. Nigbati wọn ndagba si, ti emi si ndi arugbo si - bi ọjọ ola ba wa, awọn ni yoo jẹ alagba ti ọla. Emi ko fẹ ki Ohùn Ọrọ Ọlọrun yii ki o ku lae. Ko tilẹ le ku; o nilati ma a tẹsiwaju. Emi ko si gba wipe a ni akoko pupọ lati mu un wa.

Ọmọ ọwọ kekere ti wọn sọ wipe o nku lọ, mo ri I wipe iwọ ti ni in nile isin lati owurọ arabinrin. Iyẹn dara. A dupẹ lọwọ Ọlọrun fun iyẹn. Oluwa dara, o kun fun aanu. Sa ti tẹsiwaju lati ma a gba ohun ti a sọ fun ọ gbọ nibẹ. Ohun gbogbo yoo dara.

6 Ṣe ẹ ngbadun ẹkọ Ọrọ naa? Ṣe ẹ nifẹ ẹkọ Ọrọ naa? Mo ro wipe, o nṣe wa nire gan ni. O fun wa ni isinmi diẹ kuro ninu gbigba adura fun alaisan, ati iran ati iwosan nipa agbara Ọlọrun. Lotitọ, lalẹ yii, a o gbadura fun awọn alaisan lẹẹkansi. A nifẹ siṣe iyẹn nigba gbogbo. A ma a nṣe itẹbọmi nigba-kiigba.

Ẹni melo lo ranti igbati mo ma a nrin ila opo waya ina? Ah, mo ti rin la awọn ila opo waya ina yẹn lọpọ igba ri, ti mo nilati rin ọgbọn ibusọ loojọ ninu aginju. Mo ni ibusọ okoo-din-lọrundunrun ibusọ ti mo nilati ma a rin. Emi a maa rin ninu igbo yẹn pẹlu aṣọ mi lọwọ mi, ti yoo si rẹ mi gidi, bi mo ti nrin lọ ninu aginju naa, ti

awọn igi ẹlẹgun yoo maa geni lara. Nigbati mo ba si ri baba agbẹ kan, a o joko labẹ igi kan, emi yoo si ba a sọrọ diẹ nipa itẹbọmi ni orukọ Jesu Kristi. Oun yoo wipe, “O dara, mo ti fẹ ṣe itẹbọmi tẹlẹ.

Emi yoo sọ fun un wipe, odo kan nṣan kọja ni tosi yii.

7 Yoo sọ pe …

Mo si ti mu ọpọlọpọ wọn lọ si odo, ti mo baptisti wọn ni orukọ Jesu. Lẹyin naa, mo tun rin oju opo ina yẹn lọ pẹlu gbogbo agbara mi. Bẹẹ ni. Lọpọ igba ni mo ṣe itẹbọmi nda ninu aṣọ iṣẹ mi, ti mo ṣẹṣẹ sọkalẹ lori opo ina kan. Mo si joko nibẹ ti mo ṣe iṣẹ lati opo kan si omiran, mo jẹ oluṣọ ati osiṣẹ ori opo nigba kan naa. Emi yoo si maa ba ẹnikan sọrọ nipa Oluwa. Oun yoo sọ wipe, “Billy, lọjọ kan, emi yoo wa si ijọ rẹ lati ṣe itẹbọmi.

Emi yoo wipe, “Kinni idi ti iwọ yoo fi sun un siwaju? A wa nitosi odo bayi, omi pupọ si wa nibi yii.” Mu wọn lẹsẹkẹsẹ. Otitọ niyẹn. Akoko naa niyẹn.

8 Iwẹfa naa sọ fun Filipi pe, “Omi niyi, kin ni o tun ndi mi lọwọ? ”Otitọ niyẹn. Ko si idiwọ mọ. Bi iwọ ba ti ṣetan, akoko naa niyẹn. Maṣe gba eṣu laaye lati fi idiwọ kan si ọ lọna. Maṣe sọ di ọla, ohun naa ti iwọ lee ṣe loni. Iwọ lee ma ni ọla. Mo ranti igba kan ti mo ṣe iyẹn, o kọ mi ni ẹkọ kan. Mo fi ohun kan ti o yẹ ki nṣe silẹ de ọjọ keji, ni ọjọ keji, o ti pẹ ju.

9 Bayi, nitootọ emi ko fẹ gba yin ni asiko bi eleyi. Sugbọn mo ni akoko to lagbara pẹlu Ọrọ naa - emi ko mọ ohun ti mo lee ṣe. Inu mi sa dun to bẹẹ ti mo fẹ rẹ ma mọ ohun ti mo nṣe. Inu mi dun gan an ni.

Ẹ jẹ ki a tẹriba fun adura ki a to ka Ọrọ naa.

Baba wa ọrun, Iwọ ni Ọlọrun alaaye, to wa laaye titi. Oorun to ṣẹṣẹ wọ yẹn naa ni Daniẹli ri, ti o wọ, oun ni Jeremaya ri, ti o wọ, oun naa ni Adamu ri, ti o wọ, Jesu si ri I, ti o wọ. Aye kan naa ni wọn si gbe ninu rẹ, ti wọn si rin ninu rẹ, Iwọ si jẹ Ọlọrun sibẹ.

Lalẹ yii, ọpọlọpọ ẹbẹ adura ni o wa. Ọkunrin ti o ni eewo to le fa iku ni ọpọlọ rẹ, arabinrin si wa ti o bẹru pe, oun ni ohun kan naa. Iwọ nikan ni ireti wa Oluwa fun nkan wọnyi. Eewo to le fa iku yẹn ti di jẹjẹrẹ, ko si ohun to le da a duro. O si ti kọja agbara awọn dokita. Sugbọn lalẹ yii, awa nlọ pẹlu kanna-kanna wa kekere bayi, a si lọ gbeja ọdọ-aguntan yẹn, lati mu un pada wa sinu agbo Baba wa. Ni orukọ Jesu Oluwa, awa doju adura wa kọ kiniun naa, lati pa a, ani eewo jẹjẹrẹ naa, a si mu wọn pada wa sinu agbo.

10 Awa si ranti Aarẹ wa ọwọn, ati arakunrin wa, Dwight Eisenhower. O ti dari ilẹ yii, Oluwa, O ti gbiyanju lati pa wa mọ kuro ninu ogun. O ṣeleri wipe ogun korea yẹn yoo dopin bi oun ba ri ọna Kankan lati dẹkun rẹ. O ṣeleri fun awọn iya yẹn wipe oun yoo mu awọn ọmọkunrin wọn pada wa sile. Sugbọn o wipe, “Emi ko le ṣe e funra mi. Ọlọrun ni o lee ran mi lọwọ lati ṣe e”. Iwọ si ran an lọwọ Oluwa, o si ti pari nisisiyi. Kin ni o de ti wọn ko fi ri otitọ yẹn ni ibẹrẹ? Ọlọrun, mo gbadura pe, ki o ran an lọwọ. Bukun ọkan akin yẹn Oluwa. A si gbadura pe ki iwọ yan olori ti o kan fun wa. Oluwa, jẹ ki ifẹ Rẹ ti O ti yantẹlẹ di mimuṣẹ.

Sugbọn Ẹni naa ti a nifẹ si lalẹ yii, yatọ si awọn ọran orilẹ ede wa, ni Ẹni nla Ologo naa ti nbọ wa gbe ijọba ailopin kan kalẹ, ti I ṣe Oluwa wa Jesu, Ọmọ Rẹ. Nigba naa, wọn yoo pa gbogbo ohun ija ogun ti, ipe yoo dun, ki yoo si si ogun mọ. Wọn yoo gbin ajara, wọn yoo si jẹ wọn. Wọn yoo kọ ile, wọn yoo si gbe ninu wọn. Ko si ni si idaamu kankan mọ.

Bukun wa bayi, bi a ti nlọ sinu Ọrọ naa. Baba, Iwọ mọ idi ti mo fi nkọ ẹkọ yii. O jẹ nitoripe, mo ni itọni pe. Iwọ fẹ ki n ṣe e ni ọna yii, ati pe, ifẹ Rẹ ni. O si jẹ eto Rẹ, ati ilana Rẹ pe, ki awọn eniyan lee mọ ipo wọn, ki wọn si gbaradi fun akoko ogun. Gẹgẹbi arakunrin wa ṣe gbadura laipẹ yii wipe, “Oluwa, iwọ ti nkọ wa lati igba pipẹ wa”. Bayi Baba, fun wa ni ipo iṣẹ wa. Fi wa soju iṣẹ sinu ohun to yẹ ki a ṣe, ki a lee wa lẹnu iṣẹ Baba wa. Nitori a beere fun un ni orukọ Jesu Ọmọ Rẹ. Amin.

11 Mo ni akoko to dara ni ọsan yii, ti mo n ba dokita to ti Lousville wa, to si gbaju-gbaja sọrọ ati nọọsi rẹ. Wọn ti gbọ nipa awọn nkan mani-gbagbe ti Oluwa. Baba nọọsi naa si jẹ dokita. Obinrin naa si wa joko ni iyara mi fun igba pipẹ lọsan yii, ti o sa a wọle wa. O si jẹ obinrin kan ti o dara pupọ, o jẹ ẹni lile kan, ọmọ ijọ Pirẹsibiteria, sugbọn o jade lọ pẹlu omije ni oju rẹ.

Ah, Ọlọrun ni awọn tirẹ nibi gbogbo, nile iṣẹ awọn oniṣegun laarin awọn nọọsi. O fẹ rẹ ẹ ma si nọọsi Kankan nile itọju alaisan ti Norton Infirmary ti emi ko jẹri fun nipa ibaptisimu Ẹmi Mimọ ati siṣe itẹbọmi ni orukọ Jesu Kristi. Ko si dokita kan ti mo ba pade ti n ko jẹri fun.

Ẹ sọ fun wọn nipa rẹ. A ko ni akoko pupọ mọ, arakunrin. Bi o ti wu ki nkan le to nihin, saa duro ki a fi kọja eemi to gbẹyin yẹn, iwọ yoo ri I wipe, o yẹ ki o ti ṣe e. Bẹẹ ni, Sa. Ma duro de igba yẹn, ẹ jẹ ki a ṣe e nisisiyi. Akoko naa niyi. Ah, wọn le tako ọ, ki wọn tahun si ọ nipa rẹ, sugbọn, wọn ko ni in lọkan bẹẹ. Wọn ko fẹ sẹ

bẹẹ gan an. Bi wọn ba ti bẹrẹ si ba ọ ja, sa a ranti wipe, wọn ko ni in lọkan bẹẹ, o sa le jẹ wipe, wọn ti kọ wọn ni ọna ti o yatọ, wọn si di iyẹn mu, nitori naa, iwọ le e ri ero wọn. Ma ṣe bawọn tahun rara, ma ṣe ba ẹnikẹni ja, sugbọn sa a ni ifẹ wọn. Ki o si gbadura fun wọn.

12 Mo ro pe a ti de ẹsẹ kẹsan. Ko da mi loju. Iyẹn jinna pupọ si ori kẹta, abi bẹẹ kọ? Sugbọn oyin ori apata ni si mi! Ranti ohun ti a nsọrọ rẹ tẹlẹ, ki a le mọ ipilẹ rẹ. Arakunrin Neville, ki ẹ fa mi ni aṣọ bi mo ba gbagbe lati wo akoko yẹn, ki n lee gbadura fun awọn alaisan. A fẹ gba gbogbo Ibukun ti o ba ṣeeṣe. Lalẹ yii, mo fẹ pe awọn eniyan wa lati gba Kristi. A o pari sori eyiti a ti nilati ka ẹyiti o ku.

Sugbọn idi fun ẹkọ yii ni, riri ipo rẹ ninu Kristi, ki o ri I wipe, kii ṣe ohun kan ti iwọ ṣeesi ta gbọn-ọn-gbọn-ọn sinu rẹ, tabi ohun kan ti iwọ yẹ fun nipa ohun kan ti o ṣe, sugbọn o jẹ ohun ti Ọlọrun ṣe fun ọ, fun ra Rẹ. Kii ṣe wipe iwọ jẹ eniyan rere to bẹẹ ti o lọ sile isin lọjọ kan, ti arakunrin kan si mu ọ lọ sibi pẹpẹ. Kii ṣe iyẹn. Sugbọn, o jẹ Ọlọrun, ṣaaju ipilẹṣẹ aye, ti O yan ọ tẹlẹ si Iye Ainipẹkun. Nigbati o ba de ibẹ lọjọ naa …..

Ko wa yanilẹnu pe, awọn alagba mẹrinlelogun, ati gbogbo wọn fi ade wọn lelẹ, olukuluku dojubolẹ, wọn ko ni akayẹ ara wọn kankan. Ko si alagba kan, oniwaasu kan tabi ẹnikẹni to yẹ. Gbogbo iyin jẹ ti Ọdọ-Aguntan naa! Ọlọrun yoo ko ohun gbogbo papọ sinu Rẹ lọjọ naa. Ah, bi o ba ṣe wipe gbogbo wa mọ Ẹni naa ti wọn kan mọ agbelebu ni.

13 A o bẹrẹ lati ẹsẹ kẹjọ bayi, lati ṣe ipilẹ kan.

Ẹyiti o sọ di pupọ fun wa ninu gbogbo ọgbọn ati oye.

Ẹniti o ti sọ ohun ijinlẹ ifẹ Rẹ di mimọ fun wa, gẹgẹbi idunnu Rẹ, eyiti o ti pinnu ninu Rẹ.

“Ijinlẹ ifẹ Rẹ.” Ṣe o ranti bi a ṣe lo akoko lori iyẹn? Ẹni melo lo wa nibi lowurọ yii? Ẹ jẹ ki a wo o. Bi a ṣe duro pẹ lori iyẹn, “Ijinlẹ ifẹ Rẹ” Bayi, ki ikan i ṣe ohun kekere kan, ijinlẹ kan ni. Ifẹ Ọlọrun jẹ ijinlẹ kan. Olukuluku eniyan ni o si nilati wa ifẹ Ọlọrun fun aye rẹ ni awari, ijinlẹ ti Ọlọrun.

Bawo ni a ṣe n mọ ọn? A fihan fun Paulu. O sọ wipe oun ko ba eniyan Kankan jiroro. Ko lọ si ile iwe Kankan, ko lọ sile ẹkọ ẹsin. Ko ni ohunkohun lati ṣe pẹlu iyẹn. Sugbọn a ṣipaya rẹ fun un lati ọdọ Jesu Kristi, ti o pade rẹ loju ọna Damasku ninu imọlẹ to jẹ Ọwọn Ina, ti o si darukọ rẹ.

Oun si lọ si Arabia, o si wa nibẹ fun ọdun mẹta. Ah, ṣe iwọ ko ro wipe akoko to dara kan niyẹn, Arakunrin Egan? Paulu wa ni Arabia fun ọdun mẹta. O kọ agọ kan fun ara rẹ nibi kan. O nrin kaakiri ninu ile, soke, sodo, pẹlu gbogbo awọn Iwe Mimọ Majẹmu Laelae. Ko tii si Majẹmu titun nigba yẹn. Paulu lo kọ ibiti o pọju ninu Majẹmu titun.

Ninu awọn Iwe Mimọ atijọ wọnyẹn, bi Ọlọrun ṣe yan wa tẹlẹ si Iye Ainipẹkun, ati pe Oun yoo ran Jesu pe ki a lee ni anfaani si Igi Iye nipasẹ irubọ Rẹ. Awọn ti o si ti mọ tẹlẹ, ni O ti pe, awọn ti o ti pe ni o ti dalare, awọn ti o ti dalare, ni o ti ṣe logo. Ọlọrun, ṣaaju ipilẹṣẹ aye ti yan wa tẹlẹ si isọdọmọ ti awọn ọmọ. Bayi, gbogbo ẹda n kerora, wọn n lakaka lati ri ifarahan-fayeri ti awọn ọmọ Ọlọrun. Ah, o nilati jẹ wipe, Paulu ni akoko to logo kan nigbati o nkọ eleyi. O wu mi ki nti wa pẹlu rẹ nigba yẹn. Iwọ nkọ?

14 Bayi o wipe, “Oun ti sọ ijinlẹ naa di mimọ.” Iwọ gba Ẹmi Mimọ laaye nigba kan, ki iwọ bẹrẹ si ka iyẹn, ki o ri bi yoo ṣe kọ ọ. Ni ọsan yii, mo lo nkan bi ọgbọn iṣẹju lati kẹkọ, lati yẹ ẹkọ naa wo. Mo tilẹ lee sọ wipe iṣẹju marundogun ni. Mo si bẹrẹ si I ka a, mo ro nipa “Ijinlẹ naa - bawo ni o ṣe jinlẹ to!” Iwe Mimọ si mu mi lọ sinu Majẹmu laelae, o tun mu mi wa sinu Majẹmu Titun, o si so wọn papọ lati ri ijinlẹ bibọ Rẹ, ijinlẹ ifẹ Rẹ, ati ijinlẹ bi a ṣe joko papọ.

Ranti wipe, a ko lee kọ eleyi ninu Ile-ẹkọ ti Ẹsin Kankan. Ijinlẹ ni. Iwọ ko le e mọ ọn nipa iwe kikọ, tabi nipa ẹkọ ẹsin. O jẹ ijinlẹ ti a ti fi pamọ lati ipilẹṣẹ aye, ti o nduro de ifarahan awọn ọmọ Ọlọrun.

15 Sọ fun mi arakunrin, sọ fun mi arabinrin, akoko wo ni a lee fi awọn ọmọ Ọlọrun han-fayeri yatọ si akoko yii? Nigba wo, ninu gbogbo itan aye, ti a lee gba gbogbo ẹda la? Ẹda funra rẹ nkerora, o nduro de akoko ifarahan naa, ki a to ṣe irubọ etutu naa, ki a to tu Ẹmi Mimọ jade, ṣaaju Majẹmu Laelae. Ko ṣeeṣe ki ifarahan ṣẹlẹ. O nilati duro de akoko yii. Bayi, ohun gbogbo ni a ti muwa, ti o ntẹsiwaju, ti o si nwa si okuta tente-ori ile, titi di ifarahan awọn ọmọ Ọlọrun, ti Ẹmi Ọlọrun si nwa sinu awọn eniyan yii ni pipe, tobẹẹ ti Iṣẹ Iriju iwaasu wọn yoo sunmọ ti Kristi, tobẹẹ ti yoo sọ Oun ati Ijọ Rẹ di ọkan ṣoṣo.

16 Ẹni melo ni o ti kọ nipa itan ti ile alaramọnda to fẹ nisalẹ to si kere lori yẹn? Mo ro pe, obinrin kan ni o nawọ soke nibi yii. O dara.

Ọlọrun kọ Bibeli Mẹta. Ọkan ninu wọn ni igbekalẹ awọn irawọ ati awọn ẹda oju ọrun. Bibeli kinni niyẹn. Eniyan nilati wo oke, ki o si mọ wipe, Ọlọrun wa lati oke. Iwọ kiyesi awọn irawọ ati igbekalẹ wọn. Njẹ iwọ ti I kọ ẹkọ nipa rẹ ri? O tilẹ sọ nipa iran kọọkan, o si sọ nipa iran ti alákàn. O sọ nipa ibẹrẹ, ibi Kristi. Kin ni ohun

akọkọ ninu igbekalẹ awọn irawọ? Wundia ni. Kin ni ohun ti o gbẹyin? Kiniun ni. Bibọ Kristi fun igba akọkọ ati bibọ Rẹ nigba keji. Gbogbo rẹ ni a kọ sinu igbekalẹ awọn Irawọ.

Bibeli keji ti a kọ ni a si kọ sinu okuta, a si pe e ni ile alaramọnda to fẹ ni isalẹ, to si kere ṣonṣo ni oke. Ọlọrun kọwe sinu awọn ile alaranmọnda naa. Bi o ba kọ ẹkọ nipa wọn, kiyesi awọn itan atijọ ati awọn ogun, bi a ṣe kọ wọn ṣaaju iparun nipa ikun omi.

17 A kọ Bibeli kẹta sori iwe - a si pe e ni Bibeli Mimọ - fun aye to kun fun awọn ọmọwe, to jafafa, to kun fun imọ, to nbọ niwaju. Bi Ọlọrun ti ṣe rinrinajo ni gbogbo iran, a ti wa ni akoko ti Leo, Kiniun; a ti wa ni akoko dide ile alaramọnda naa ni ade. A wa ninu Iwe Ifihan, ni ori ti o gbẹyin. Imọ ijinlẹ sọ wipe, a ti wa ni iṣẹju mẹta ki agogo mejila oganjọ oru to lu. Ah, ronu nipa ibiti a wa!

Si kiyesi, jẹ ki a wo ile alaramọnda naa. O rọrun. O duro gẹgẹbi ile origun mẹta.

Nigbati a wa ni ibẹrẹ ijọ akọkọ, lẹyin naa, igba atunṣe ijọ ni akoko Luther, bi ẹnikan ba sọ wipe Kristẹni ni oun, o lee jasi iku fun un. Wọn yoo pa a nitoripe o sọ pe Oun jẹ Kristẹni. Nitori naa, ni gbogbo igba ijọ, ni gbogbo akoko, inunibini wa lodi si onigbagbọ tootọ, “Gbogbo ẹniti o gbe igbe aye iwa-bi-Ọlọrun ni yoo jiya inunibini”. Ni igba ijọ Luther, o buru lati jẹwọ pe o tẹle Luther. Wọn yoo ka ọ si agba-were-mẹsin kan, wọn si lee pa ọ. Lọpọ igba ni wọn nfi wọn kọ ara igi, ti wọn yoo si dana sun wọn, fun jijẹ ọmọ ijọ Luther.

18 Lẹyin naa, ijọ kere si, bi o ti ri ninu ile alaramọnda naa. O wa si ipele oore-ọfẹ miran, ti I ṣe isọdi-mimọ - akoko Wesley, nigbati o tako ijọ Anglican, ti o waasu isọdimimọ. Wọn kere si niye, wọn si pe wọn ni, alakatakiti, agbawere-mẹsin.

Ẹni melo nibi, ni o ti jẹ ọmọ ijọ Mẹthodisti ri? Ilaji yin. Njẹ ẹ mo wipe Ijọ Mẹthọdisti fẹẹ gba Ẹmi Mimọ nigba kan ri? Mo ti lọ si ijọ Mẹthodisti, mo si ri wọn ti wọn ṣubu silẹ, wọn si bu omi le wọn loju, wọn fi ohun afẹtẹgun fẹ wọn, wọn di Ẹmi Mimọ lọwọ lati wa sori wọn. Otitọ niyẹn. Ni ori oke Kentucky, nibiti a ti ni awọn Mẹthọdisti ojulowo. Ẹyin wọnyi jẹ oludarapọ mọ ijọ; sugbọn a ti ni ojulowo awọn Mẹthodisti ati Baptisti ni igba yẹn. A ma a nlọ sibi pẹpẹ, a o si gba ara wa lẹyin titi ti a o fi ri ohun kan gba. A ma a n gbadura yanju - a si ngbe igbe aye titun lẹyin naa.

Sugbọn nisisiyi, ẹyin nwa lati kọ orukọ sinu iwe kan, ẹ o si wipe, “Ọmọ Ijọ Mẹthodisti ni mi” Wọn yoo si fi agolo iyọ wọn omi diẹ si ọ lara, o si pari niyẹn. Ẹ njade lọ ma a wọ ṣokoto penpe, ati ọda oju, ẹ nlọ sibi tẹtẹ, ere ẹsin, ẹ nta tẹtẹ, ati kalokalo, ati ohun gbogbo bẹẹ - ẹ si jẹ ọmọ Ijọ Mẹthodisti daradara sibẹ. Kii ṣe ojulowo Mẹthodisti niyẹn, ọmọ ijọ lasan ni. Otitọ niyẹn. Bẹẹ gẹlẹ ni o ri pẹlu Baptisti ati Pirẹsibiteria pẹlu awọn ti o ku.

19 Gẹgẹ bi David Duplessis ti wipe, “Ọlọrun ko ni ọmọ-ọmọ” Ọlọrun ko ni ọmọ-ọmọ ri. O ni awọn ọmọ, sugbọn ko ni ọmọ-ọmọ. Otitọ niyẹn. Awọn ti o si wa sinu Ijọ Mẹthodisti, tabi Ijọ Pẹntikọsita, tabi Ijọ Baptisti, nitori pe iya rẹ tabi baba rẹ jẹ ọmọ Ijọ naa, iwọ jẹ ọmọ-ọmọ. Awọn obi rẹ jẹ ọmọ Ọlọrun, iwọ si jẹ ọmọ-ọmọ Ọlọrun, ko si ni ohun to jọ iyẹn. Ijọ ni ọpọlọpọ iyẹn, sugbọn Ọlọrun ko ni ọmọ-ọmọ.

20 Kiyesi I, bi ijọ tootọ ṣe nkere si bayi, bi o ti ntẹsiwaju. Igba Ijọ ti awọn afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ si bẹrẹ. O daju pe, iyẹn ge ọpọlọpọ nkan kuro. Kin ni o si ṣe? O fi Ijọ Methodisti ati Lutherian silẹ sẹyin.

Nisisiyi, Ẹmi Mimọ ti tẹsiwaju lọ kuro ni igba ti awọn afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ. Kin ni wọn ṣe? Wọn ti fi eniyan-ṣe-adari-dipo-Ẹmi Mimọ, wọn wipe, “Awa ni ”Apejọpọ Ọlọrun (Assemblies of God) Awa ni ẹgbẹ to gba wipe, “Ọkan dondo ni Ọlọrun” (Oneness). Awa ni “Meji ni Ọlọrun” (Twoness) Awa ni “Ijọ Ọlọrun” (Church of God) Awa ni “eyi” ati “tọhun” Wọn wipe, “Bi iwọ ko ba jẹ ara ijọ wa, bi orukọ rẹ ko ba si ninu Iwe Ijọ wa, iwọ ko lee de ọrun”. Ah, radarada bẹyẹn! Emi ko bikita bi iwọ jẹ Baptisti, Methodisti, Pirẹsibiteria. Iwọ ti ni orukọ rẹ ninu Iwe Iye nigbati Ọlọrun kọ ọ sibẹ.

Bi a ba yan ọ tẹlẹ si Iye Ainipẹkun, Ọlọrun yoo pe ọ lọna kan tabi omiran. Dajudaju yoo ṣe e. “Gbogbo awọn ti Baba ti fifun Mi, yoo tọ Mi wa.” Ijọ ti o wu ki iwọ lọ, iyẹn ko ni ohun Kankan I ṣe pẹlu rẹ. Ijọ to fẹkọ-kẹkọ-rọpo-Ọrọ-Ọlọrun ko le e ṣe ọ ni ire kan, sugbọn o le e ṣe idiwọ pupọ fun ọ lati tẹsiwaju pẹlu Ọlọrun, sugbọn ko le e ṣe ohun miran. Iwọ n kojọpọ pẹlu adalu onigbagbọ ati alaigbagbọ. Ni tootọ, a nba iyẹn pade nibikibi ti a ba nlọ, wọn tilẹ ni iyẹn ni Ọrun pẹlu. O dara. Sugbọn iwọ nfi igbagbọ sinu Ijọ ẹlẹkọ-adamọ rẹ. Wo Jesu. Oun ni iwọ nilati kọbi ara si, ti o nilati gbagbọ.

21 Bi ijọ si ti ntẹsiwaju, ẹni melo ni o ti ka nipa ile alaramọnda to fẹ nisalẹ, to kere loke? Mo gbagbọ pe, obinrin yii nawọ rẹ pe oun ti ka a. Ṣe o mọ wipe, a ko fi igba kan ri de ile alaramọnda naa lori? Ko ni ibi tente-ori ti o pari rẹ. Wọn ko tilẹ ri I, wọn ko ri okuta-tente-ori naa. Wọn ko mọ ohun ti o ṣẹlẹ si i. Tori kin ni ko ṣe ni okuta-tente-ori naa? Nitoripe, wọn kọ Ọ silẹ nigba ti O wa. Oun ni okuta ti awọn ọmọlẹ kọ silẹ. Otitọ niyẹn. Sugbọn a o fi de e. Bẹẹ ni.

Awọn okuta ti o si kangun si ibiti okuta-tente-ori yẹn yoo duro le nilati jẹ okuta ti o dabi ti tente-ori naa, to bẹẹ ti yoo ba a mu rẹgi. Ile alaramọnda naa pe to bẹẹ ti o ko le e fi abẹfẹlẹ kọja laarin awọn okuta rẹ, bi awọn okuta naa ṣe ba ara dọgba to, iṣẹ ọna to lẹwa pupọ ni. Ọkọọkan wọn lee wọn ẹgbẹgbẹrun iwọn kilo, ti wọn si gbe soke loke bẹẹ, ti a si gbe wọn papọ ni pipe.

22 Bi Ọlọrun ṣe nkọ ijọ Rẹ niyẹn. A so wa papọ ni pipe, gẹgẹbi ọkan kan pẹlu isọkan. Ẹnikan yoo wipe, “Awọn ọmọ ẹyin Luther nigba yẹn ko ni ohun kan.” Maṣe gba iyẹn gbọ. Awọn ọmọ ẹyin Luther yoo jade wa ninu ajinde, gẹgẹbi awọn to ku. Awọn Baptisti, Pirẹsibiteria ati awọn to ku yoo jade wa ninu ajinde yẹn. Idi si niyẹn loni, ti awọn eniyan kan wipe, “Ah, isọji nla kan yoo ṣẹlẹ, ti yoo si gba ọgọrun miliọnu awọn Pẹntikosita la. A o gba gbogbo wọn la, igbasoke kan yoo si ṣẹlẹ”. Iwọ nṣe asiṣe. Igbasoke yẹn yoo jẹ ẹgbẹẹgbẹrun lọna ọgọrun melokan, otitọ niyẹn, sugbọn, a o mu wọn wa lati ẹgbẹrun mẹfa ọdun lati ibẹrẹ aye.

Eniyan maa nrin ninu imọlẹ, bi imọlẹ ṣe ntọ wa- Oun a si maa rin afara kọja nigba ti o ba de ibi afara. Bi o ba si kọ imọlẹ naa, oun yoo joko sinu okunkun sibẹ. Sugbọn bi o ba ntẹsiwaju pẹlu imọlẹ naa, yoo ma a ni imọlẹ.

23 Bayi, bibọ Jesu Oluwa ti sun mọle to bẹẹ gẹ lati ibẹrẹ ti I ṣe idalare, isọdimimọ, ati baptisimu Ẹmi Mimọ, titi ti a fi wa ni akoko bibọ ti okuta tente-ori yẹn. Ijọ nilati dabi Kristi ni pipe, tobẹẹ ti ijọ ati Kristi yoo di ọkan naa nipa Ẹmi kan naa. Bi Ẹmi Kristi ba si wa ninu rẹ, yoo mu ki iwọ gbe igbe aye Kristi, ki o si ṣe iṣẹ Kristi. Ẹniti o ba gba Mi gbọ, iṣẹ ti Emi ṣe ni oun yoo ṣe pẹlu“ gẹgẹ bi Jesu ti wi. Bayi, a ni iṣẹ Iriju Iwaasu kan ti nbọ wa ti o dabi ti Jesu gẹlẹ. Kin ni iṣẹ Iriju Iwaasu naa n tọka si? Bibọ Oluwa ni.

Kiyesi ni aye loni, ki o si wo ohun ti Khrushchev nsọ pẹlu ohun gbogbo to nṣẹlẹ wọnyi, ati gbogbo ija nla kaakiri aye. Aye lee di eeru nigba-kii-gba, otitọ niyẹn. A si mọ wipe iyẹn ti sunmọle. Enikẹni ti o ni ori pipe, lee ka ninu iwe iroyin tabi ki o feti si redio, yoo mọ wipe, o ti sunmọle. Ranti wipe Kristi yoo mu Ijọ Rẹ lọ ki iyẹn to ṣẹlẹ. Nitori naa, ni bibọ Oluwa ti sunmọle to? Boya ki isin yii to pari ni. A ti wa ni opin aye. Otitọ ni, dajudaju.

24 Kiyesi Ijọ bi o ti wa, ati bi o ti ntẹsiwaju. Ẹyin olukọtan, ẹ saa wo o ni ọkan yin. Wo Ijọ ti Luther ni abẹ idalare, ti o jade lati inu ijọ Katoliiki taara. Wo bi o ṣe siṣẹ. Ẹ si wo Wesley bi o ti sunmọ otitọ si, ti o gba isọdimimọ ti o kọ Iwe Mimọ si. Wo aarin Ijọ ti Wesley. Eyi ti o tẹle e ni ijọ Pẹntikọsita - ti iran ti Pẹntikọsita si wọle pelu idapada awọn ẹbun Ẹmi. Si wo iran to nwọle bayi ti o wa si okuta tente ori ile naa. Ṣe ohun ti mo nsọ ye ọ? Eyi nfi bibọ Oluwa han. Ọlọrun ati gbogbo ẹda nduro de Ijọ naa lati duro si Ipo rẹ.

25 Iṣoro to wa loni ni wipe, ọpọ eniyan ni ko ni oye kankan nipa igbala ọkan wọn. Mo lọ lati ṣe ayẹwo ara mi, ki nto lee lọ si oke okun. Ẹyin akiri-waasu mọ nipa eleyi. Nigba ti mo nṣe ayẹwo naa lọwọ, wọn mu mi jade kuro ni iyara kan. Mo si ti mu ohun kan bi ogi. Mo jade, mo si joko lati duro fun ọgbọn iṣẹju ki a le ṣe ayẹwo nipa onjẹ naa.

Mo wo ayika ninu ile naa, mo si ri obinrin kekere kan, oun si dabi ẹniti ko lee pẹ ti yoo fi ku; o jẹ alaisan. Mo si lọ lati ọdọ ẹnikan si omiran titi ti mo fi de ọdọ obinrin naa. O dabi ẹni pe, o ti fẹrẹ ku. Mo sunmọ ọdọ rẹ, mo si wipe “Ẹ pẹlẹ mama yii”.

Obinrin naa wipe, “Bawo ni?” Ara rẹ ko da!

Mo wipe, “Kin ni o ṣe ọ?”

O wipe, “Mo lọ si Tucson lati lọ ki ọmọbinrin mi. Aisan si kọlu mi. Wọn ko si mọ ohun to nṣe mi”

Mo wipe “Ohun kan ni mo fẹ beere lọwọ rẹ. Mo jẹ oniwaasu ihinrere. Ṣe Kristẹni ni ọ? Ṣe iwọ ti pese ara rẹ silẹ, bi iku ba de?”

O wipe, “Ọmọ ijọ bayi-bayi ni oun”

Mo wipe, kii ṣe ohun ti mo beere lọwọ rẹ niyẹn. Ṣe Kristẹni ni ọ, ti a kun pẹlu Ẹmi Mimọ, ti o si ṣetan lati jẹ ipe Ọlọrun bi o ba pe ọ kuro laye? Ohun ti mo sọ ko tilẹ ye obinrin naa. Ah, ipo aimọkan to ṣe ni laanu ti aye yi wa!

26 Bayi, “O ti sọ ijinlẹ ifẹ Rẹ di mimọ fun wa” Jẹ ki nka ohun kan. Jẹ ki a ṣi si ijinlẹ ifẹ Rẹ. Jẹ ki a ṣi si Heberu bayi. Ori keje Heberu mo fẹ ka ohun kan ti yoo munu yin dun nigbati a ba ri I wipe awa njoko papọ ninu awọn ọrun, Heberu ori keje;

Nitori Melkisedeki yii, Ọba Salẹmu alufaa Ọlọrun Ọga-ogo.

27 Kin ni ijinlẹ naa bayi? Ijinlẹ kan niyi, kiyesi I. Tani Ẹni yii? Fifi ijinlẹ ifẹ Rẹ han. (Mo nduro ki gbogbo yin ṣi Bibeli yin) Heberu, ori keje. Paulu kan naa ti o sọrọ ni Galatia:

Nitori Melkisedeki yii, Ọba Salẹmu Alufa Ọlọrun Ọga-Ogo Ẹniti O pade Abrahamu bi o ti n pada lati ibi pipa awọn ọba bọ, ti o si sure fun un.

Ẹniti Abrahamu si pin idamẹwa ohun gbogbo fun, ni ọna kinni, ni itumọ rẹ - Ọba Ododo, ati lẹyin naa, Ọba Salẹmu, (Tani Ẹni yi?) ti iṣe ọba alaafia.

Laini baba, laini iya, laini itan iran, bẹẹni ko ni ibẹrẹ ọjọ tabi ọjọ aye……

28 Tani ọkunrin yii? Ta ni gan? Oun ko ni baba, ko si ni Iya. Ko ni ọjọ ti aye rẹ bẹrẹ, tabi ọjọ ti aye rẹ pari, ti o si ku. O pade Abrahamu ti o npada bọ lẹyin ti o ti pa awọn ọba yẹn. Kin ni o nṣe? O lọ lati gba Lọti, arakunrin rẹ pada. O si pa awọn ọba yẹn, ti pa awọn ọba yẹn ti pa bi mẹwa si marundogun ati ijọba wọn. Sugbọn Abrahamu di awọn iransẹ rẹ ni amure, o si lọ gba arakunrin rẹ, o pin awọn iransẹ rẹ ni oru. Ṣe o ri igba ti o gba Lọti? Ni akoko oru. Ah, arakunrin, awa nrin ninu okunkun bayi. Imọlẹ kan ṣoṣo ti a ni ni imọlẹ ti ihinrere. Sugbọn Abrahamu pin awọn iransẹ rẹ, o si ri Lọti mu pada wale.

Ninu irinajo rẹ pada wale, lẹyin igbati ogun ti pari, o pade Melkisedeki. Ẹ jẹ ki a lọ si Jẹnẹsisi ori kẹrinla. Jẹnẹsisi 14:18. Eyi ni Abrahamu ti o npadabọ lẹyin ti o ti pa awọn Ọba tan. O mu Lọti pada wa ati gbogbo awọn eniyan ti wọn ti ko lọ.

29 Gbogbo rẹ.

Gẹgẹbi Dafidi ti ṣe lọ lati gba ọdọ-aguntan yẹn silẹ. Kin ni Dafidi ṣe? O mu kanna-kanna kekere naa, o si gba Ọdọ-aguntan kuro lẹnu kiniun. Ẹ ro nipa kanna-kanna lati fi bori Kiniun. Tani ẹni naa laye yii ti yoo ṣe iyẹn? Sọ fun mi, ẹnikan nibi yii ti yoo ṣe iyẹn, ki o na ọwọ soke? Emi yoo sọ fun ọ kiakia pe, irọ lo pa. Iwọ ko ri i ki emi nawọ mi soke. Rara, emi ko ni dojukọ Kiniun pẹlu ibọn kekere. Sugbọn Dafidi doju ija kọ kiniun pẹlu kanna-kanna ti I ṣe awọ kekere kan ti o ni okun meji lara rẹ.

Nigbati akoko si to, ti Golayati fọnnu, Dafidi lọ dojukọ Golayati pẹlu Kanna-Kanna. O si wipe, "Ọlọrun ọrun ti ranmilọwọ lati gba ọdọ-aguntan kuro lẹnu kiniun ati beari" O mọ wipe, kii ṣe kanna-kanna, sugbọn agbara Ọlọrun ni o lọ pẹlu rẹ. Ọlọrun ni O mu ọdọ-aguntan yẹn pada.

30 Ohun ti a sọ loni niyẹn. Ọlọrun ni awọn Dafidi kaakiri, ti wọn nbọ awọn aguntan Baba. Ni igba kọọkan, eewo to lee fa iku yoo wa, tabi jẹjẹrẹ kan tabi ohun miran, yoo si kọja agbara awọn onisegun, Iyẹn ko ni jẹ iṣoro fun Dafidi yẹn. Oun yoo lọ taara lati lọ gba ẹni naa kalẹ pẹlu kanna-kanna yii: "Beere ohunkohun ni orukọ Mi, a o si ṣee: Emi ko bikita, awọn onisegun lee fi rẹrin, gbogbo eniyan si lee fi ṣe ẹlẹya, oun yoo lọ gba a kalẹ sibẹ, yoo si mu aguntan yẹn pada wa sinu agbo. Bẹẹ ni sa. Yoo wipe, "Ọmọ Ọlọrun ni, mu ọwọ rẹ kuro lara rẹ!" Yoo si kọlu Kinniun yii yoo lu bolẹ. Nigbati Kiniun si dide si I, o gba irugbọn rẹ mu, o si pa a." Ọmọkunrin kekere yii, ti o le ma ju iwọn ọgọrin tabi aadọrun lọ.

31 Kiyesi bayi. Melkisedeki Ọba Salẹmu tii ṣe Ọba alaafia - nitootọ, Salẹmu wa lẹyin oke kan nibẹ. O jẹ Ọba Jerusalẹmu. Ẹniti o jẹ niyẹn. Jerusalemu si ti kọkọ njẹ Salẹmu, to tumọ si "alaafia". Oun si ni Ọba Jerusalẹmu ti a ti kọkọ npe ni Salẹmu. Oun ni Ọba Ododo, Ọba alaafia, Ọba Salẹmu. Ko si ni baba, ko ni iya, ko ni ibẹrẹ ọjọ, ko si ni opin ọjọ Rẹ, ko ni itan iran. Ta ni ẹni yii? Kiyesii. Lẹyin ti ogun naa pari tan, ti Abrahamu ti ṣẹgun tan, kiyesi ohun ti O sọ. Jẹnẹsisi ori kẹrinla, ẹsẹ kejidinlogun.

Mẹlkisedeki Ọba Salẹmu si mu onjẹ ati ọti waini jade wa: Oun a si maa ṣe alufaa Ọlọrun Ọga-Ogo.

O si sure fun un, O si wipe, "Ibukun ni fun Abramu, ti Ọlọrun Ọga-Ogo Ẹniti o ni Ọrun ohun aye.

Olubukun si ni Ọlọrun Ọga-Ogo ti o fi Ọta rẹ le ọ lọwọ. Oun si da idamẹwa ohun gbogbo fun Un.

Ẹ jẹ ki a ka diẹ siwaju si.

Ọba Sodomu si wi fun Abramu pe, Da awọn eniyan fun mi, ki o si mu ẹru fun ara rẹ.

Abramu si wi fun Ọba Sodomu pe, mo ti gbe ọwọ mi soke si OLUWA, Ọlọrun Ọga-Ogo, ti o ni Ọrun ohun aye,

Pe, emi ki yoo mu lati fọnran owu titi de okun bata, ati pe emi ki yoo mu ohun kan tii ṣe tirẹ, ki iwọ ma ba a wipe. Mo sọ Abramu di Ọlọrọ:

Bikoṣe kiki eyiti awọn ọdọmọkunrin ti jẹ…..

32 Kiyesi Melkisedeki yii, ni kete ti o pade Abrahamu ti o npada bọ lati ibiti o ti pa awọn ọba naa. A nsọ awọn ijinlẹ Ọlọrun di mimọ bayi - ta ni ọkunrin yii? Wọn ko ri itan iran kankan nipa rẹ, nitori pe ko ni Baba, ko ni iya, ko ni ọjọ kan ti o bẹrẹ. Ko ni ọjọ kan ti o ku. Nitori naa, ẹni yowu ti I ba a jẹ, O wa laaye sibẹ loni. Oun ko ni

ibẹrẹ, nitori naa, ko lee jẹ ẹlomiran yatọ si El, Ela, Elohimi tii ṣe Ẹni ti o dawa ni oun nikan lati Ainipẹkun, Ọlọrun Olodumare!

Jesu ni Baba kan, Jesu ni iya kan. Jesu ni ọjọ ti a bi I, Jesu si ni ọjọ ti ọjọ aye Rẹ pin. Sugbọn Ọkunrin yii ko ni baba tabi iya. Jesu ni Baba ati Iya. Ọkunrin yii ko ni baba tabi iya. Amin. Kin ni O si ṣe? Nigbati ogun pari, lẹyin ti Abrahamu ti mu ipo rẹ?

Lẹyin ti Ijọ ti mu ipo rẹ, a pe wa si ipo isọdọmọ ti awọn Ọmọ Ọlọrun nipa Ẹmi Mimọ. Nigbati ẹni kọọkan ba si ti mu ipo rẹ (ohun ti Ọlọrun ti pe e si lati ṣe) ti o si duro titi de opin irin-ajo naa, ti o nlọ gba awọn ti o ti ṣako, ti o ti sọnu.

33 Ṣaaju, Paulu mu gbogbo ibẹru kuro ninu rẹ, o wipe, “Bi a ba ti pe ọ nitootọ - ti ki i ṣe wipe a kan fi ẹkọ ẹsin kan ru ọkan rẹ soke lasan - bi a ba tun ọ bi nipa Ẹmi Mimọ nitootọ, a jẹ wipe Ọlọrun ti yan ọ tẹlẹ ṣaaju ipilẹṣẹ aye, O si ti kọ orukọ rẹ sinu Iwe Iye ti Ọdọ Aguntan, bayi, awa ti wa papọ lati joko ninu awọn Ọrun ninu Jesu Kristi. Awọn eniyan Mimọ, orilẹ-ede Mimọ, awọn eniyan ọ̀tọ̀, Olu alufaa, ti wọn nrubọ ti ẹmi si Ọlọrun, ti I ṣe eso ti ètè wa, ti n fi iyin fun orukọ Rẹ”.

Awọn eniyan wa, wọn si wipe, “Ori awọn eniyan naa ti daru.” Dajudaju, bẹẹ ni. Ọgbọn Ọlọrun jasi iṣiwere loju eniyan, ọgbọn eniyan si jẹ isiwere si Ọlọrun. Awọn mejeeji tako ara wọn.

34 Sugbọn ijọ kan ti a kun pẹlu Ẹmi, ti o kun fun agbara Ọlọrun, ti njoko ninu awọn Ọrun, ti nrubọ mimọ, nipa iyin si Ọlọrun ti Ẹmi Mimọ nsiṣẹ laarin wọn, ti o ntu aṣiri ẹṣẹ, ti o si npe ikuna wọn jade kuro, ti o nmu wọn tọ, ti O si nmu wọn wa ni isọkan. Nitori kin ni? Irubọ to kun fun ẹjẹ yẹn wa niwaju Ọlọrun ni gbogbo igba.

Ranti bayi (a kọ nipa rẹ lowurọ yii), ẹjẹ naa kọ ni o gba ọ la. Sugbọn a pa ọ mọ sinu igbala nipa ẹjẹ naa. Sugbọn a fi Oore-ọfẹ gba ọ la nipa igbagbọ. Iwọ gba a gbọ. Ọlọrun kan ilẹkun ọkan rẹ nitoripe o ti yan ọ tẹlẹ. Iwọ boju woke, o si gba A gbọ. Bayi, ẹjẹ naa ṣe etutu fun ẹṣẹ rẹ. Ranti pe, mo sọ wipe Ọlọrun ko da ẹlẹṣẹ lẹbi fun ẹṣẹ rẹ. Ẹlẹṣẹ ni oun lati ibẹrẹ. Ọlọrun nda Kristẹni lẹbi fun ẹṣẹ rẹ. Nitori pe o si ti da a lẹbi. Kristi gba idalẹbi wa. Nitori naa, “Ko si idalẹbi mọ bayi fun awọn to wa ninu Kristi Jesu, ti wọn ko rin nipa ti ara, sugbọn ti wọn nrin nipa ti Ẹmi”.

Bi iwọ ba si ṣe ohunkohun ti o kuna, iwọ ko mọnmọ ṣe e. Iwọ ko le mọnmọ dẹṣẹ. Ẹnikan to jade lọ, to lọ mọnmọ dẹṣẹ, ko ti I wa sinu ara yẹn rara. Sugbọn ẹnikan to ti wa ninu ara Kristi ti ku, a si ti fi iye rẹ pamọ sinu Ọlọrun nipasẹ Kristi, ti a fi edidi ti Ẹmi Mimọ di I, eṣu ko tilẹ lee ri i, oun ti jina pupọ ninu ara naa. Oun nilati jade wa kuro nibẹ ki eṣu to le e ri I mu.

Nitori ti iwọ ti ku.

35 Sọ fun oku kan wipe, alagabagebe ni I ṣe, ki o ri ohun ti yoo ṣẹlẹ. Iwọ ta a ni ipa lẹgbẹ ki o wipe, “Iwọ alagabagebe yii” Oun ko ni sọ ọrọ Kankan. Bẹẹ ni, yoo sa sun sibẹ ni. Ẹnikan to si ti ku ninu Kristi, iwọ lee pee ni “alagaba-gebe”, pee ni ohun ti o wu ọ lati pe e, oun ko ni doju kọ ọ nitori rẹ. Bi o ba ṣe ohunkohun yoo lọ si ibi kan, yoo si gbadura fun ọ. Otitọ niyẹn.

Sugbọn ọpọlọpọ wọn ni o wa laaye sibẹ. Mo ro wipe awọn oku ni o yẹ ki a sin. Awọn ti o ti ku ninu Jesu Kristi ni a maa nsin nipa itẹbọmi. Nigba miran, a maa nsin awọn to wa laaye, ti wọn ni arankan, ati ija pupọ. Wọn si wa ninu ijọ, sugbọn a ko lee ya wọn sọtọ. Sugbọn Ọlọrun mọ wọn. O mọ awọn eniyan tirẹ. O mọ awọn aguntan Rẹ. O mọ ohun ẹnikọọkan. O mọ awọn ọmọ Rẹ. O mọ ẹniti o lee pe jade, o mọ awọn ti o ti yantẹlẹ. O mọ awọn ti o fi nkan wọnyi fun, ati awọn ti o nfi ara Rẹ han nipasẹ wọn.

Ọlọrun lee ni igbẹkẹlẹ ninu awọn ọmọ Rẹ; nipa ohun ti wọn nilati ṣe, o mọ wipe wọn yoo ṣe ohun ti o tọ, ṣe iwọ gbagbọ pe Ọlọrun ṣe bẹẹ?

36 Satani sọ fun Ọlọrun lọjọ kan wipe, “Bẹẹ ni, Iwọ ni iranṣẹ kan.”

Ọlọrun wipe, “Ko si ẹnikan laye to dabi rẹ. Ọkunrin pipe ni” Ọlọrun ni igbẹkẹlẹ ninu rẹ.

Satani wipe “Bẹẹ ni o ni ohun gbogbo to fẹ. Iwọ fi le mi lọwọ fun igba kan. Emi yoo mu ki o fi Ọ bu lojukoroju”.

Ọlọrun wipe, “Mo fi le ọ lọwọ, sugbọn o ko gbọdọ gba ẹmi rẹ” Satani si ṣe ohun gbogbo ti o le e ṣe lai gba ẹmi rẹ.

Sugbọn kinni Jobu ṣe? Njẹ o fi Ọlọrun ré bi? Nigbati o pa awọn ọmọ rẹ! ti o si ṣe gbogbo nkan wọnyi si i? Jobu ko beere pe, bawo lo ṣe le ri bẹẹ. O dojubolẹ, o si jọsin si Ọlọrun. Halleluya! O wipe, “Oluwa n fun ni, Oluwa si n gba pada, Ibukun ni fun orukọ Oluwa”!

Ọlọrun mọ igbẹkẹle ti O ni ninu Jobu. Ọlọrun mọ bi Oun ṣe le gbẹkẹ le mi to.

Sugbọn ohun ti a nsọ bayi ni fifi ọmọ yii sipo.

37 Ninu Bibeli, nigbati ogun ba pari, kinni o kan? Kin ni a ma nṣe nigbati ogun ba ti pari? Ṣe iwọ mọ ohun ti a maa nṣe? A pade Melkisedeki. Jẹ ki a ṣi si Mattiu 16:16. Rara, Matiu 26:26 ni mo fẹ ki a ṣi, nitoripe onjẹ alẹ to gbẹyin ni mo fẹ ka nipa rẹ. Matiu ori kẹrindinlọgbọn ẹsẹ kẹrindinlọgbọn.

Bi wọn si ti njẹun, Jesu mu akara, o si sure, o sibu u, o si fifun awọn ọmọ ẹhin Rẹ, o wipe, “Gba, jẹ; eyiyi ni ara Mi.

O si mu ago, O dupẹ, o si fifun wọn, O wipe, Gbogbo yin, ẹ mu ninu rẹ.

Nitori eyi ni ẹjẹ Mi, ti majẹmu titun, ti a ti ta silẹ fun ọpọ eniyan fun imukuro ẹṣẹ (awọn Kristẹni to ṣe ohun ti ko tọ).

O dara, fetisilẹ si ẹsẹ kọkandinlọgbọn bayi.

…Sugbọn mo wi fun yin, lati isisiyi lọ, Emi ki yoo mu ninu eso ajara yii mọ, titi yoo fi di ọjọ naa, nigbati Emi yoo ba a yin mu titun ni ijọba Baba Mi.

Kin ni? Ohun kan naa ti Melkisedeki ṣe lẹyin ti Abrahamu ti gba ipo rẹ. Ti o fi awọn ọkunrin rẹ si eto, ti o si bori ogun naa, oun si wa sile, Melkisedeki si wa pẹlu akara ati waini. Lẹyin ti ogun naa ba pari, a o jẹ onjẹ alẹ Oluwa pẹlu Jesu Oluwa ninu aye titun naa. Ah, Ibukun ni fun Orukọ Oluwa.

O dara.

38 …….awọn ijinlẹ ifẹ Rẹ, ni ibamu pẹlu ifẹ inu Rẹ (pada si Iwe Efesu bayi) ti o ti pinnu ninu ara Rẹ.

Fun iṣẹ iriju ti kikun akoko naa……

Ranti wipe, a ṣẹṣẹ kaa tan ni ninu Efesu ori kinni, ẹsẹ kẹwa.

Fun iṣẹ iriju ti kikun akoko naa……

Bayi, a ti kọ wipe, ẹkunrẹrẹ akoko nduro de kin ni? Ekunrẹrẹ gbogbo akoko, nigbati ẹṣẹ yoo ti pari, ti iku yoo ti pari, ti aisan yoo ti pari, ẹṣẹ yoo ti pari, akoko ti gbogbo idibajẹ ati awọn ohun to ti dibajẹ, ti eṣu ti bajẹ yoo dopin - nigbati akoko funra rẹ yoo dopin. Kiyesi.

Eyi ti yoo jẹ jade ni kikun akoko, lati ṣe akọjọpọ awọn ohun ti Ọrun ati ti aye labẹ or ikan, ani Kristi.

“Ko ohun gbogbo papọ ninu Kristi” Gẹgẹbi mo ti sọ lowurọ yii, gbogbo awọn ohun iyebiye ti a lee ri wọnyi, a le e mu wọn jade ni Jẹnẹsisi, Eksodu, Lefitiku, titi de ifihan, gbogbo wọn yoo si fi Jesu han. Bi iwọ ba mu Josefu, ati Abrahamu, Isaaki, Jakobu, Dafidi, gbogbo awọn ẹkọ iyebiye nipa awọn ọkunrin Ọlọrun wọnyẹn - iwọ yoo rii ti I ti wọn yoo fi Jesu Kristi han fayeri. Ki Oun lee ko ohun gbogbo sọkan ninu Jesu Kristi“

39 Jẹ ki a tẹsiwaju diẹ bayi. Ẹsẹ ikọkanla wipe:

Ninu Ẹniti awa ti gba ogun ini kan

Ah, ogun ini kan. Ẹnikan nilati fi ohun kan silẹ fun ọ lati jogun rẹ. Ṣe bẹẹ ni? Ogun ini wo ni a ni? Ogun ini wo ni mo ni? Emi ko ni ohun kan. Sugbọn Ọlọrun fi ogun ini kan silẹ fun mi, nigbati o fi orukọ mi sinu Iwe Iye ti Ọdọ-Aguntan ṣaaju ipilẹṣẹ aye.

Ah, iwọ wipe, “Wo o, Jesu ni o ṣe Iyẹn nigbati o ku fun ọ” Rara. Kọ ṣe bẹẹ. Jesu wa lati sanwo fun ogun ini yẹn fun mi. Iwọ ka ẹsẹ ti o kan:

Ninu Ẹniti awa ti gba ogun-ini kan, gẹgẹbi ipinnu Ẹniti nsiṣẹ ohun gbogbo gẹgẹbi imọ ifẹ Rẹ.

40 Ọlọrun, ṣaaju ipilẹṣẹ aye, gẹgẹ bi a ti mu Un wa ninu ẹkọ fun yin. Bi a ṣe ri I wipe, Ọlọrun dawa ni Oun nikan; Bi o ṣe jẹ wipe ninu Rẹ ni ifẹ wa, ninu Rẹ ni agbara lati jẹ Ọlọrun, agbara lati jẹ Olugbala (ko si ti si ohun kan ti o sọnu) Inu rẹ ni ipa lati jẹ Oluwosan. Eyi ni awọn iwa ati ipa Rẹ. Ko si ti si ohun kan nibẹ, Nitori naa, oun funrarẹ mu awọn nkan wọnyi jade, ki o lee fi gbogbo nkan wọnyi han nipasẹ ọkunrin kan yii, ti I ṣe Jesu Kristi. Ah, oju ko ti I riri, eti ko tii gbọ ri…. Ko yani lẹnu ti o fi jẹ ijinlẹ kan.

41 Wo o, o ti yan wa tẹlẹ si ogun ini kan. Bi mo ba jẹ ajogun si ohun kan. Bi Ọlọrun ba nkanlẹkun ọkan mi wipe, “William Branham. Emi ti pe ọ ṣaaju ipilẹṣẹ aye, lati waasu ihinrere”. Mo ni ogun inikan - ogun ini ti iye ainipẹkun. Lẹyin naa, Ọlọrun ran Jesu lati mu ki ogun ini naa di arigbamu fun mi, nitori pe, ko si ohun kan ti

mo lee ṣe lati jogun rẹ. Ko jẹ okodoro si mi tẹlẹ. O wa nibẹ. Ko si ohun ti mo lee ṣe nipa rẹ. Sugbọn, ni ẹkunrẹrẹ akoko, nigbati o wu u, Ọlọrun ran Jesu - Odo Aguntan naa, ti a ti pa ṣaaju ipilẹṣẹ aye. A ta ẹjẹ Rẹ silẹ, ki emi lee lọ si ogun ini mi. Lati jẹ kin ni? Kin ni ogun-ini naa? Ti ọmọ, lati jẹ ọmọ Ọlọrun.

42 Bayi, eleyi yoo ya ọ lẹnu pupọ. Njẹ iwọ mọ wipe awọn ọmọ Ọlọrun tootọ jẹ Ọlọrun kekeke? Ẹni melo ni o mọ iyẹn? Tani o mọ pe Jesu sọ bẹẹ? Jesu wipe, “Njẹ ofin yin, ninu Bibeli ko ti sọ wipe, Ọlọrun ni ẹyin iṣe?” Ti o si jẹ wipe, ninu Jẹnẹsisi 2, Ọlọrun pe wọn ni Ọlọrun kekeke, nitori pe wọn ni isakoso lori gbogbo aye. O fun Adamu ni isakoso lori ohun gbogbo. Oun si sọ ipo rẹ nu gẹgẹbi Ọlọrun, o sọ ipo rẹ nu gẹgẹbi Ọmọ Ọlọrun. O sọ ipo rẹ nu gẹgẹbi alakoso aye, satani si gba a.

Sugbọn arakunrin, awa nduro de ifarahan awọn ọmọ Ọlọrun, ti yoo pada wa, ti yoo si gba isakoso aye lẹẹkansi. A nduro de ẹkunrẹrẹ akoko, nigbati ile nla alaramọnda yẹn yoo gba ade-tente-ori rẹ, ti a si ri ifarahan-fayeri ti awọn ojulowo ọmọkunrin Ọlọrun, nigbati agbara Ọlọrun yoo di mímọ̀ (Halleluyah!) ti a o si gba gbogbo agbara ti satani ni kuro lọwọ rẹ. Bẹẹ ni sa, gbogbo agbara jẹ ti Jesu.

43 Oun ni Ọrọ (Logọsi) ti o jade lọ kuro ninu Ọlọrun. Otitọ niyẹn. Iyẹn ni Ọmọ Ọlọrun. Lẹyin naa o da ọkunrin, ti I ṣe Ọlọrun kekere yẹn. Jesu wipe “Bi wọn ba pe awọn ti Ọrọ Ọlọrun tọ wa (awọn wolii) ni Ọlọrun kekeke” Ọlọrun si sọ ọ funra Rẹ, wipe Ọlọrun kekeke niwọn. O sọ fun Mose pe, “Mo ti fi ọ ṣe Ọlọrun, mo si fi Aroni ṣe wolii rẹ” Amin. Ah, ah, Mo le jọ bi aṣiwere-ẹlẹsin kan, sugbọn emi kii ṣe were. Ah bi oju rẹ ba lee ṣi lati ri awọn nkan wọnyẹn! O dara.

O da eniyan ni Ọlọrun kekere kan, alakoso kan ninu ilẹ ijọba rẹ. Ilẹ ijọba rẹ si kaakiri gbogbo ilẹ aye. O ni isakoso lori rẹ. Nigbati Jesu si de, ti o jẹ Ọlọrun kanṣoṣo, ti ko ni ẹṣẹ, o fi eleyi daniloju. Nigbati iji nja, O wipe, “Alaafia, dakẹ jẹ!” Amin. Nigba ti O si sọ fun igi ọpọtọ pe, “Ki ẹnikẹni maṣe jẹ eso lori rẹ mọ” o ri bẹẹ.

Lootọ, lootọ ni mo wi fun yin (Ẹyin Ọlọrun kekeke) bi iwọ ba wi fun oke yii wipe, 'ṣidi' ti iwọ ko si ṣe iyemeji ni ọkan rẹ, sugbọn ti o gbagbọ wipe, ohun ti iwọ sọ, yoo ṣẹlẹ bẹẹ, iwọ lee ri ohun ti o sọ gba.

44 Pada si Jẹnẹsisi si ojulowo naa.

Kin ni gan? Bayi, aye ati ẹda nkerora, wọn nke, ohun gbogbo lo nlakaka. Kin ni? Fun ifarahan awọn ọmọ Ọlọrun, nigbati awọn ọmọ Ọlọrun tootọ, ti a tunbi ti a kun yoo sọrọ, ti Ọrọ wọn yoo si siṣẹ bẹẹ. Mo gba gbọ pe a ti wa ni bebe rẹ bayi. Bẹẹ ni, Sa. “Sọ fun oke yii pe ṣidi, jẹ ki o ri bẹẹ”

“Arakunrin, mo fẹ ki a ṣe ohun yii fun mi. Mo jẹ onigbagbọ ninu Jesu Kristi”

“Mo fi fun ọ ni orukọ Jesu Kristi Oluwa” Amin Yoo farahan - fayeri.

“Ah, arakunrin awọn ọgbin mi njona loko. Mo nilo ojo”

“Emi yoo ran ojo si ọ ni orukọ Jesu Oluwa. Bẹẹ ni sa” Ah, ẹda gbogbo nduro, wọn nkerora fun ifarahan-fayeri ti awọn ọmọ Ọlọrun! Ọlọrun ti yan an tẹlẹ lati ipilẹṣẹ. O ti fun eniyan ni isakoso ohun gbogbo.

45 O fifun Jesu Kristi. Jesu si fun wa ni iṣẹgun naa ni orukọ Rẹ, pẹlu idaniloju yii wipe “Beere ohunkohun lọwọ Baba ni Orukọ mi” Emi yoo si ṣe e“ Ah, Arakunrin Palmer! Aye nduro de ifarahan awọn ọmọ Ọlọrun, ki wọn wa si ipo naa gẹgẹbi ijọ Rẹ!

Bi mo ti sọ tẹlẹ, Iwe Efesu ni o duro fun Iwe Joshua ninu Majemu titun, o jẹ bi Joshua ṣe fi awọn eniyan si ipo wọn. Bayi, bi wọn ko ba duro jẹ ẹ, ti o fi Efremu sibi kan, ti o si lọ si ilẹ ti Manase, ti omiran si lọ sibomiran ti wọn ntahun sira wọn, bawo ni wọn ṣe lee wa ni isọkan? Nigbati ọkan wipe, “Emi jẹ Baptisti, emi jẹ Mẹtọdisti, emi jẹ Pẹntikọsita, emi jẹ ọkan-bi-ika-kan ni Ọlọrun, omiran wipe, awọn Ọlọrun meji ni, ati bẹẹ bẹẹ lọ” bawo ni ẹ o ṣe ṣe e? Duro jẹ! Ọlọrun yoo fi Ijọ Rẹ si ipo gẹgẹbi awọn ọmọkunrin ati ọmọbinrin Ọlọrun.

Ọlọrun jẹ ki nle wa laye lati ri I ni mo gba ni adura. O sunmọ tosi, to bẹẹ ti mo fẹrẹ le na ọwọ mi kan an. Ohun ti mo ti nfẹ lati ri niyẹn. Mo nduro de igbati a o ri amukun loju titi bi a ti nlọ, ti o yarọ lati inu iya rẹ wa. “Wura tabi fadaka, awa ko ni” Ah, a nduro de ifarahan awọn ọmọ Ọlọrun, Halleluyah, nigbati Ọlọrun yoo sọ ara Rẹ di mímọ̀ - nigbati wọn yoo da aisan duro, wọn yoo da jẹjẹrẹ duro, wọn yoo da arun duro.

46 Iwọ ro wipe jẹjẹrẹ jẹ ohun Pataki kan? Bibeli wipe, akoko nbọ ti ara awọn eniyan yoo maa jẹra, ti awọn igun yoo maa jẹ ara-eniyan ki wọn to ku. Aisan jẹjẹrẹ yoo dabi ẹhin-didun bi a ba fi we aisan to nbọ wa. Sugbọn ranti pe, a ti pasẹ fun awọn ohun buburu ti yoo ṣẹlẹ lọjọ naa wipe, ko gbọdọ fọwọ kan awọn to ni edidi Ọlọrun lori wọn. Ohun ti a nlakaka fun niyẹn bayi, ki a le wọle, ki a si gba ipo wa ninu ijọba Ọlọrun ki awọn iyọnu buburu naa to de. Ah eyi ti dara to! Ni saa ti ẹkunrẹrẹ akoko, ti a ti ni ogun ini naa.

Ninu Ẹniti awa ti gba ogun ini naa, awa ti a ti yantẹlẹ.

47 Bawo ni a ṣe fun wa ni ogun ini wa, ni ọna wo ni? Nipa iyantẹlẹ. Iyantẹlẹ si jẹ “Imọtẹlẹ” Bawo ni Ọlọrun ṣe mọ wipe Oun lee gbẹkẹle ọ lati jẹ oniwaasu? Nipa imọtẹlẹ Rẹ ni. “Kii ṣe ti ẹniti o fẹ, tabi ti ẹniti nsare, sugbọn Ọlọrun ti O nṣe aanu” Bẹẹ ni, iyantẹlẹ ni. O mọ ohun ti o wa ninu rẹ. O mọ inu rẹ ki o tilẹ to wa saye. O mọ inu rẹ ki aye to wa rara. Oun niyẹn, Ọlọrun ailopin. Ailopin! Awa ni idiwọn, awa lee ronu nipa akoko.

48 O ti jẹ ohun to tobi pupọ si mi. Ohun to ṣẹlẹ si mi gan, kọja oye mi. Nigbati mo duro sibẹ nikọja akoko yẹn fun iṣẹju diẹ. “Ko si ọla, ko si ana, ko si aisan, ko si ibanujẹ. Ko si idiwọn inu didun, ayọ ti ko ni idiwọn ni” Ah ah! Mo duro nibẹ, mo si wipe, “Kin ni eyi?”

Ohùn yẹn wipe, “Eyi ni ifẹ pipe, ohun gbogbo ti iwọ ti fẹran ri, ati ohun gbogbo to nifẹ rẹ ni a ti fifun ọ nibi yii”

Wọn wipe, “Iwọ yoo fawa le Jesu Oluwa lọwọ nigbati O ba de, gẹgẹ bi eso iṣẹ Iransẹ rẹ” Mo si ri awọn obinrin to lẹwa yẹn nibẹ, ti gbogbo wọn nyọ mọ mi, ti wọn nkigbe“ ”Arakunrin mi ọwọn!“ Mo ri awọn ọkunrin yẹn, pẹlu irun to de ọrun wọn, ti wọn nsare, ti wọn ngba mi mu, ti wọn nwipe, ”Arakunrin wa ọwọn!“

Mo si ro o wipe, “Kin ni eyi tumọ si?”

O wipe “Awọn eniyan rẹ ni wọn”

Mo wipe, “Awọn eniyan mi kẹ? Awọn ẹbi Branham ko le pọ to bayi. Ẹgbẹlẹgbẹ ni awọn yii”

O wipe, “Awọn ti o jere fun Ọlọrun ni wọn! (Halleluyah) Awọn ti o jere fun Ọlọrun niwọn. Ṣe o ri obinrin ti o duro sibẹ yẹn (obinrin naa lẹwa rekọja)? O ti le ni aadọrun ọdun laye nigba ti o mu u gba Ọlọrun gbọ. Idi niyẹn to fi nkigbe pe ”Arakunrin mi Ọwọn“ Oun ko lee di arugbo mọ. O ti rekọja iyẹn. Oun si wa ninu didan ti ọdọbinrin. Bi o ti duro sibẹ yẹn, oun ko lee mu omi tutu lati pa oungbẹ, ko nilo rẹ, ko le fi ara lelẹ lati sun, nitoripe ko lee rẹ ẹ. Ko si ana, ko si ọla, a ti wa ni ainipẹkun bayi. Sugbọn lọjọ ologo kan Ọmọ Ọlọrun yoo wa, a o si ṣe idajọ rẹ gẹgẹbi Ọrọ ti o waasu si wọn” Ah, arakunrin!

Mo wipe, “Ṣe Paulu nilati mu ẹgbẹ tirẹ wa?

“Bẹẹ ni”

Mo wipe, “Mo waasu Ọrọ naa gẹgẹbi Paulu ti sọ ọ. Emi ko yẹ̀ kuro rara, emi ko gba ẹkọ adamọ ti ijọ Kankan. Mo duro ti I gẹlẹ”

Gbogbo wọn si kigbe soke ni isọkan wipe, “A mọ bẹẹ! Awa si nsimi pẹlu idaniloju. Iwọ yoo fa wa le Oluwa lọwọ, lẹyin naa gbogbo wa yoo pada lọ si aye lẹẹkan si, lati gbe nibẹ titi lae” Ah, ah!

49 Nigba naa ni mo bẹrẹ si pada si aye. Mo wo ara mi to ti ndarugbo, to si hunjọ nibiti mo dubulẹ si, ti ara naa ni aisan, ti o si ti jiya, mo si ri awọn ọwọ mi labẹ ori mi, mo ro o wipe, Ah! Ṣe mo nilati pada sinu ohun yẹn lẹẹkansi?“

Nigba naa, mo bẹrẹ si gbọ ohun yẹn, “Iwọ tesiwaju! Ma a lakaka siwaju si!”

Mo wipe, “Oluwa, emi ti ma ngba iwosan nipa agbara Ọlọrun gbọ. Emi yoo tẹsiwaju lati ma a gba a gbọ. Sugbọn, emi yoo lakaka fun awọn ọkan yẹn, nitori naa, ran mi lọwọ. Mo fẹ ni pupọ nibẹ, jẹ ki nwa laaye Oluwa, ki emi si jere Miliọnu kan si.

50 Emi ko bikita fun àwọ̀ wọn, tabi ẹkọ wọn, tabi orilẹ-ede wọn, oun ti wọn le jẹ, ọkan naa ni gbogbo wọn nigbati wọn ba de ọhun. Gbogbo ààlà ti iyapa yẹn ti kọja lọ. Ah mo lee ri awọn obinrin yẹn bi wọn ti lẹwa to. Wọn ni irun gigun de ẹyin wọn, asọ wọn si gun de isalẹ, wọn ko wọ bata. Mo wo awọn ọkunrin pẹlu irun to yi ọrun wọn po, awọn ti irun wọn pupa, onirun dudu ati orisirisi awọ. Wọn si nfi ọwọ wọn gba mi mu mọra. Mo nimọlara wọn gẹgẹbi mo ti nimọlara ọwọ mi loju mi bayi.

“Wọn sa a ngba mi mu mọra wọn - ko si imọlara ti obinrin ti o wa laye yii. Bi o ti wu ki o jẹ ẹni mimọ to, tabi ẹniti iwọ jẹ, iru oniwaasu ti o jẹ, ko si ọkunrin ti o lee jẹ ki obinrin fi ọwọ gba oun mọra ti ko ni ni imọlara eniyan. Otitọ niyẹn. Sugbọn arakunrin, nigbati o ba kọja aye yii si ibẹyẹn, ko ri bẹẹ mọ. Ah ah! Ko ṣeeṣe lati ni imọlara ẹṣẹ nibẹ. Gbogbo rẹ jẹ ojulowo arakunrin ati ojulowo arabinrin. Ko si Iku, ibanujẹ, owu, tabi ohunkohun bẹẹ. Ko si ohun ti ko yẹ kan to le wọ ibẹ. Ohun gbogbo jẹ pipe.

Ohun ti mo nla kaka fun niyẹn. Ohun ti mo nfini sipo fun niyẹn.

51 Idi niyẹn ti mo fi wa sile isin, ti mo ngbiyanju lati fi ijọ si ipo rẹ. Mo nsọ fun arakunrin ati arabinrin pe, ohun kan ṣoṣo ni o le wọ ibẹ yẹn, iyẹn ni ifẹ pipe. Ki iṣe nitoripe iwọ ṣe olootọ si Ijọ Apẹjọpọ Branham, tabi Ijọ Metọdisti tabi Baptisti. Awọn nkan yẹn dara. O yẹ ki o jẹ olootọ si ijọ rẹ. Sugbọn ẹyin ọrẹ, o ju iyẹn lọ. Ki i ṣe

nitoripe o ti fi ede titun sọrọ, o ti jo ninu Ẹmi, tabi nitoripe o ti le ẹmi eṣu jade tabi o ti fi igbagbọ si oke ni idi. Gbogbo iyẹn ni o dara. Sugbọn sibẹ, a fi igbati ifẹ pipe yẹn ba wa ninu rẹ. Nibẹ yẹn ni ifẹ pipe wa.

52 ….A ti gba ogun ini kan. (kin ni a jogun? Iye ainipẹkun nigbati a ti yan wa tẹlẹ!

Ni ọna wo? Ṣe ẹnikẹni loye iyẹn? Ṣe iwọ ke pe Ọlọrun? Rara, Ọlọrun ni o pe ọ. Ko si ẹnikan ti o wa Ọlọrun ri; Ọlọrun ni O nwa eniyan. Jesu wipe, "ko si ẹniti o le tọ mi wa laiṣe wipe Baba Mi: kọkọ fa a" Iwa ẹda eniyan ni lati maa sa fun Ọlọrun.

Ohun tọ si n da mi laamu niyẹn, lati waasu si ẹyin eniyan ki ẹ si duro soju kan sibẹ. Ẹ má duro soju kan naa ti ẹ wa tẹlẹ. Ẹ yipada bayi! Gbọ bi mo ti nsọ ọ bayi. "Bayi ni Oluwa wi" Emi ko ti i pe ara mi ni wolii ri (Emi kii ṣe wolii) sugbọn ẹyin npe mi ni wolii yin, tabi wolii kan. Aye gba iyẹn gbọ. Miliọnu ati miliọnu eniyan kaakiri aye lo gba bẹẹ. Mo ti ba miliọnu mẹwa si mejila eniyan sọrọ taara. Mo ti ri iran ẹgbẹgbẹrun lọna mẹwa, ati iṣẹ ami ati iṣẹ ara, ti ọkan ko si kuna ninu wọn. Otitọ si ni iyẹn. Oun ti jẹ ki nsọtẹlẹ ti ko si kuna ri rara. Emi yoo pe ẹnikẹni nija fun eleyi. Otitọ niyẹn.

Emi ko pe ara mi ni wolii, sugbọn fetisi mi:

53 Bayi ni Oluwa wi, yoo gba ifẹ pipe lati fi ọ si ibẹ yẹn, nitori kiki ohun to wa nibẹ niyẹn. Bi o ti le wu ki o ṣe iṣẹ isin to, bi iṣẹ rere ti o ṣe ti lee to, tabi ohun ti o ti ṣe, iyẹn ko ni ṣe Pataki ni ọjọ yẹn. Yoo gba ifẹ pipe. Nitori naa, ohunkohun ti o wu ki o ṣe, pa ohun gbogbo ti sapakan titi ti iwọ yoo fi kun fun ifẹ Ọlọrun, titi ti iwọ yoo fi nifẹ awọn ti o korira rẹ.

Gẹgẹbi mo ti sọ lowurọ yii, ohun gbogbo ti mo jẹ ni oore-ọfẹ. Ọpọ eniyan ni o wipe, "Bi iwọ ba ranmilọwọ, emi yoo ran ọ lọwọ. Bẹẹ ni. Bi iwọ ba ṣe ohun kan fun mi, emi yoo ṣe ohun kan fun ọ" kii ṣe oore-ọfẹ niyẹn. Oore-ọfẹ ni wipe bi iwọ ba nilo iranlọwọ mi, emi yoo ṣe e, yala o ranmilọwọ tabi o ko ranmilọwọ. Bi o ba gba mi loju, ti o si nilo ẹniti yoo ba ọ ha ẹhin rẹ, emi yoo ba ọ ṣe e. Bi o ṣe ri niyẹn. Ṣe ohun kan. Emi ko gbagbọ ninu fifi iṣẹ dipo igbala. Mo gbagbọ pe iṣẹ jẹ nipa ifẹ. Iṣẹ jẹ ifarahan wipe oore-ọfẹ ti gba wa la.

Emi ko gbe ni otitọ si iyawo mi nitoripe ki o ma ba a kọ mi silẹ. Mo ṣe e nitoripe mo nifẹ rẹ.

54 Emi ko waasu ihinrere nitoripe mo le lọ si ọrun apaadi bi nko ba waasu. Mo n waasu ihinrere nitoripe mo nifẹ Rẹ. Dajudaju. Njẹ o ro wipe emi yoo lọ si oke okun ninu awọn baluu to n fi soke sodo, ti mọnamọna nkọ, to dabi ẹni pe, nigba-kiigba, a le ṣubu sinu okun ti awọn eniyan nkigbe, ti awọn miran nfi ibẹru ka, "Maria mimọ" ati ohun gbogbo bẹẹ? Ti awọn eniyan bẹrẹ si lo nkan fun aabo wọn, ti atukọ si wipe "A ni epo ti o lee gbe wa fun iṣẹju marundogun si, emi ko si mọ ibiti a wa." Njẹ o ro wipe n o lọ fun ki nle e gbadun lọ?

Njẹ o ro wipe emi yoo lọ sinu aginju nibiti awọn jagunjagun ara Germany nilati wa yimika ni alaalẹ lati mu mi de ibi ipade ati lati mu mi jade (titi ti Ẹmi Mimọ fi bẹrẹ si ṣe iṣẹ iyanu) Awọn onijọba ko-S'Ọlọrun ti wọn ṣetan lati fi ibọn pa mi lati ibusọ kan pẹlu ibọn to ni dingi to nri ibi to jina - njẹ o ro wipe ọrọ eré ni o mu mi lọ? Sugbọn ohun kan ninu mi - ifẹ ni. Eniyan ni awọn naa, ti Kristi ku fun. Paulu wipe, "Emi ṣetan, kii ṣe lati lọ si ilu Jerusalemu nikan, sugbọn mo nlọ sibẹ ki a le kan mi mọ agbelebu. Mo nlọ lati ku pẹlu nitori iṣẹ Oluwa" Ifẹ ni o nrọ wa lati ṣe ohun kan. Otitọ niyẹn gẹlẹ.

55 Bi o ba jẹ wipe nitori owo ni mo ṣe nwaasu ni, emi ko ba ma ni igbese ẹgbẹrun lọna ogun dọla lalẹ yii. Rara sa, nitoripe pe emi iba ti pa diẹ mọ ninu ẹgbẹlẹgbẹ Miliọnu ti a ti fifun mi. Ọkunrin kan ran ọtẹlẹmuyẹ (FBI) si mi pẹlu miliọnu kan abọ dọla gẹgẹbi Sọwedowo. Mo wipe "Ẹ da a pada. Ki i ṣe tori owo ni a fi nwaasu. Kii ṣe ọrọ towo. Emi ko waasu ihinrere fun owo. Kii ṣe fun iyẹn, nitori ifẹ ni.

Ohun ti mo fẹ ṣe ni wipe, nigbati mo ba rekọja eemi to gbẹyin yẹn, ti o si le jẹ ni iṣẹju marun si i bayi, o le e jẹ wakati meji si isisiyi, o si le jẹ ni aadọta ọdun si - Emi ko mọ igba ti yoo jẹ. Sugbọn igba ti o ba ṣẹlẹ, ti mo de ibẹ, mo fẹ ri didan ti awọn ọdọ ti wọn nkigbe wipe "Arakunrin mi ọwọn. Arakunrin mi ọwọn" ohun ti o wa lọkan mi niyẹn. Idi niyẹn. Emi ko lodi si ọ lati jẹ ẹnikan to yatọ, sugbọn mo n gbiyanju lati fi ọ le ọna ti o tọ. Ọna lati wọle niyẹn. Kii ṣe ijọ rẹ, kii ṣe Ijọ ẹlẹkọ adamọ rẹ, sugbọn ibi titun ninu Kristi. Àh áh àh!

56 Ninu ẹniti awa ti gba ogun ini kan, gẹgẹbi a ti yan wa tẹlẹ ni ibamu pẹlu ifẹ Ẹniti nṣe ohun gbogbo gẹgẹbi igbimọ ifẹ Rẹ:

Fetisilẹ. A o danuduro lẹyin iṣẹju diẹ si. Fetisilẹ bayi ki a to pari.

Ki awa ki o le e jẹ fun iyin ogo Rẹ awa ti a ti ni ireti ṣaaju ninu Kristi.

Kiyesi eleyi bayi, finifini. Mu aṣọ ihinrere wọ. La eti rẹ daradara, fetisilẹ gidigidi. Ẹsẹ kẹtala bayi:

Ninu Ẹniti ẹyin pẹlu, nigbati ẹ ti gbọ Ọrọ otitọ ni, ihinrere igbala yin (Igbagbọ nwa nipa gbigbọ Ọrọ Ọlọrun) Lẹyin ti ẹ ti gbọ otitọ.

Kin ni otitọ? Ọrọ Ọlọrun ni. Ṣe otitọ niyẹn? Johanu 17:17, ẹyin to nkọ ọ silẹ. Jesu wipe, “Sọ wọn di mimọ, Baba, nipasẹ otitọ, Ọrọ Rẹ ni otitọ”

57 Nigbati ẹyin ti gbọ ọrọ otitọ ni, ihinrere igbala yin.

Igbala wo ni o n gbiyanju lati sọ fun wọn? Pe a ti yan wọn tẹlẹ ṣaaju ipilẹṣẹ aye (ṣe bẹẹ ni) si isọdọmọ awọn ọmọ Rẹ. A yàn wọn tẹlẹ si Iye Ainipẹkun. Bayi, lẹyin ti iwọ ba ti wa sinu Iye ainipẹkun - lẹyin ti a ti gba ọ la, ti a sọ ọ di mimọ, ti a kun ọ pẹlu Ẹmi Mimọ - iwọ ti di ọmọ; Ọlọrun si fẹ fi ọ sipo, ki iwọ ba le siṣẹ fun Ijọba Rẹ ati Ogo Rẹ.

Ihinrere niyẹn. Ti o jẹ wipe, o kọkọ gbọ ọrọ naa: “Ronupiwada ki o si ṣe itẹbọmi ni orukọ Jesu Kristi Oluwa fun imukuro ẹṣẹ. Ileri naa wa fun gbogbo awọn atipo to wa loju ọna naa. Bi iwọ ba fi ile rẹ silẹ lalẹ yii, gẹgẹbi ẹlẹṣẹ, ti o wipe, ”Emi yoo lọ sile ijọsin Branham Tabernacle“ Ọlọrun fun ọ ni anfaani naa lalẹ yii. Ohun kan ni o wa laarin iwọ ati ilẹ Ileri. Kin ni ilẹ ileri naa? Ẹmi Mimọ ni.

Ohun ti o wa laarin Joshua ati ilẹ ileri ni Odo Jọdani. Otitọ niyẹn gẹlẹ.

58 Mose, ti i ṣe akawe Kristi, darí awọn ọmọ Israẹli de aala ilẹ ileri. Mose ko mu awọn ọmọ wọ ilẹ ileri; Joshua ni o mu wọn wọle, ti o si pin ilẹ naa fun wọn. Jesu san owo itanran naa, o dari wọn de ati gba Ẹmi Mimọ. Ọlọrun ran Ẹmi Mimọ lati kun wọn, o si fi Ijọ si Ipo rẹ, gẹgẹbi ẹni kọọkan, ti o kun un pẹlu iwalaaye Rẹ. Ṣe o ri ohun ti mo nsọ? Gbogbo rẹ ninu Jesu Kristi - bi Ọlọrun ti yan wa tẹlẹ si ipe ihinrere yii.

Paulu, ni Galatia 1:8, sọ pe, “Bi angẹli kan ba wa lati waasu ohunkohun miiran, jẹki o di ẹni ifibu” - otitọ naa, ihinrere. Fetisilẹ nisisiyi bi a ṣe n kaa siwaju lati pari ẹṣẹ naa:

……Ihinrere igbala yin: ninu Ẹniti, lẹyin ti ẹ ti gbagbọ, a fi ileri Ẹmi Mimọ ṣe edidi yin.

59 Bibeli wipe, ni opin ọjọ, ẹgbẹ eniyan meji ni yoo wa. Ọkan ninu wọn yoo ni edidi ti Ọlọrun, ẹgbẹ keji yoo ni ami ẹranko naa. Ṣe bẹẹ ni? Ẹni melo ni o mọ iyẹn? Bi o ba ṣe wipe, edidi ti Ọlọrun ba jẹ Ẹmi Mimọ nigba naa, ami ẹranko yoo jẹ aini Ẹmi Mimọ. Bibeli si wipe, awọn ẹmi mejeeji yoo sunmọ ara wọn pupọ, tobẹẹ ti yoo tan ayanfẹ gan jẹ bi o ba jẹ pe o ṣeeṣe. Ko lee ṣe bẹẹ, nitoripe ati yan wọn tẹlẹ si Iye ainipẹkun.

60 Ijọ nlọ gẹgẹbi awọn Wundia mẹwa to lọ pade Oluwa, gbogbo wọn ni a sọ di mimọ, ẹni mimọ. Awọn marun jẹ ko-ṣeku-ko-sẹyẹ, wọn si gba fitila wọn laaye lati ku, marun si ni ororo ninu atupa wọn. Ipe si jade pe, “Kiyesi I, ọkọ iyawo ti de” Awọn marun to ni ororo si jade lọ si ase alẹ ti igbeyawo, a si fi awọn to ku silẹ ni ita, nibiti ẹkun ati ipayin keke yoo wa. Murasilẹ, nitori iwọ ko mọ iṣẹju ti Oluwa yoo de. Kin ni ororo sapẹrẹ ninu Bibeli? Ẹmi Mimọ ni.

61 Si ẹyin onigbagbọ ọjọ satide, ọjọ keje ọsẹ, ti ẹ sọ wipe ọjọ keje ni edidi Ọlọrun, ẹ so Iwe Mimọ kan ti o fidi rẹ mulẹ. Bibeli sọ wipe edidi Ọlọrun ni Ẹmi Mimọ. Kiyesi eleyi. Wo ẹsẹ kẹtatala bayi.

….lẹyin ti ẹyin gbagbọ, a fi ileri Ẹmi Mimọ ṣe edidi yin.

Ṣi si Efesu 4:30, mo gbagbọ pe ohun ni. Efesu ori kẹrin, ẹsẹ ọgbọn. Bẹẹni. Ohun ni 4:30.

Ma si ṣe mu Ẹmi Ọlọrun binu, ẹniti a fi ṣe edidi rẹ titi di ọjọ Irapada.

62 Titi di igba wo? Nigbati iwọ ba ti gba Ẹmi Mimọ nitootọ, bawo ni yoo ṣe pẹ to pẹlu rẹ? Ṣe titi di isọji to nbọ ni? Titi ti Iya agba yoo fi ṣẹ̀ ọ? Tabi titi ti ọga rẹ yoo fi ba ọ wi? Titi di ọjọ Irapada rẹ ni! Halleluyah!

Lẹyin ti iwọ ba ti ku ti iwọ ti kọja lọ si ilẹ naa, ti iwọ si duro pẹlu awọn olufẹ rẹ, a si kun ọ pẹlu Ẹmi Mimọ sibẹ. (Iwe Mimọ niyẹn) Iwọ yoo ri bi o ṣe ri bayi, sugbọn iwọ ti wa ninu ara miran. Iwọ saa parọ ile ni. Ile ti isisiyi ti darugbo. Ile naa ko ṣee tun ṣe mọ, o ti di ogbo, o ti ra. Otitọ ni. Nitori naa, iwọ sa a fi ile na silẹ, o si jẹ ki o ra danu, o kọja lọ sinu ile titun. Ṣe otitọ niyẹn? “Nitori bi agọ ti aye yi ba wo lulẹ awa ni omiran ti o nduro”

63 Ṣe ẹ ranti bi a se kọ́ iyẹn ni ijelo? Nigbati ọmọ kekere kan ba ndagba ninu ile-ọmọ iya rẹ, ti ara rẹ ntapa, ti o si ntọ soke sodo nibẹ. Sugbọn ni kete ti o ba jade ninu iya rẹ si aye, ohun ti yoo kọkọ ṣẹlẹ ni pe, ara ti ẹmi kan wa ti yoo wọnu ara ti a fojuri yẹn. Boya dokita ni o mi ọmọ naa tabi o gba a diẹ, ọmọ naa yoo kigbe sita, “wa a a! wa a a!”. Lẹsẹkan naa ni yoo ma a fi ẹnu wa ọmu iya rẹ ki awọn ọmu yẹn lee mu wara wa.

Ọmọ maluu kekere kan, ni kete ti o ba jade lati inu iya rẹ, yoo dide duro lori awọn ẹsẹ rẹ lẹyin iṣẹju diẹ. Kin ni oun yoo ṣe? Yoo lọ taara sibi ọmu iya rẹ lati mu wara rẹ. Halleluyah!

Bẹẹ ni, Sa, nigbati a ba bi ara ti aye yii, ara ẹmi kan wa to nduro de e lati gba a.

Nigbati ara ti aye yi ba si wo lulẹ, ọkan wa to nduro lọhun lati gba a. A sa nkuro ni ọkan lọ sinu omiran, a nparọ ile-gbe wa. Ara kiku yii nilati gbe ara aiku wọ, Ara idibajẹ, to ti hunjọ, to ti tẹ̀ba nitori ogbo yoo di titun.

Sugbọn ki yoo yipada ni iwa ẹda rẹ rara, - nigbati o ba farahan lọhun, yoo ni ẹmi kan naa.

64 Jẹ ki n fun ọ ni ohun kayefi kan, sugbọn Bibeli ni. Lẹyin naa, n o fun ọ ni ohun kan ti yoo ṣalaye rẹ. Kiyesi eleyi. Nigbati Saulu Ọba, ti a le fiwe oniwaasu ijọ ẹlẹkọ adamọ ni igba yẹn, ti o si fi ejika ati ori ga ju gbogbo eniyan lọ ti o si nbẹru. Ko mọ ohun ti o le ṣe nipa iṣẹ agbara to ga ju ẹda lọ. Dafidi nilati wa gba ọdọ-aguntan kuro lẹnu kiniun, o si pa Golayati. Kiyesi i. Saulu ti fi Ọlọrun silẹ to bẹẹ ti o korira Oniwaasu ti wọn pe ni gbara-yilẹ mimọ yii. Dipo ki o si fọwọ-kọwọ lati ran an lọwọ; o pẹhinda lodi si i. Aworan ohun to nṣẹlẹ gan ni yẹn gẹlẹ loni. O lodi si i.

65 Awọn melo ninu yin lo wa nibi nigbati mo kọkọ jade lọ ni ibẹrẹ, ti mo waasu nipa Dafidi to pa Golayati? Diẹ ninu awọn ara atijọ yẹn wa nibi. Mo tun ti npese silẹ lati jade lọ lẹẹkan si lori eleyi. Ranti, a ri ohun ti o ṣẹlẹ lọjọ Aiku to kọja? O ti nbẹrẹ si kọja si ipele miran. Ipele keji iṣẹ Iriju iwaasu ti Dafidi. Otitọ niyẹn gẹlẹ. To si jẹ wipe, Oun di Ọba lori Israeli. Kiyesi iṣẹ iriju iwaasu naa bayi, bi o ti nlọ si ipele miran to ga ju ti tẹlẹ lọ. Gẹgẹ bẹẹ ni Dafidi ti se. Kiyesi bi eleyi ṣe nwa bayi - Nigbati Ọlọrun mu ki Dafidi jade wa ti o si pa Kiniun naa, o si pa beari naa, lẹyin naa, o pa Filistini naa.

Bayi, akoko kan de ti Ọlọrun fi ẹmi eṣu kan fun ọkunrin atijọ yii. Lati ṣe kin ni? Lati korira Dafidi.

66 (Ẹ fetisilẹ bayi ẹyin ara, ati ẹyin ti ẹ o gbọ fanran yii, bi iwọ ba lodi si mi, dariji mi. Wo o, mo fẹran rẹ. Emi yoo pade rẹ lẹyin aye yii lọnakọna, nitoripe, bi iwọ ba jẹ iransẹ Ọlọrun emi yoo pade rẹ) Sugbọn mo fẹ sọ eleyi. Idi niyi: nitoripe Saulu ri wipe Dafidi ni ohun kan ti oun ko ni. Kin ni o ṣẹlẹ?

Ọmọkunrin kekere kan ti ko dun wo loju, Bibeli sọ pe eniyan rírán kan ni. Oun si jade lọ sibẹ. Saulu si gbe ihamọra rẹ le e, mo woye pe apata saulu gun de ẹsẹ Dafidi. O wipe, “Gbe ohun yii kuro lori mi.” Boya o fun un ni oye ọmọwe kan, Phd tabi LL D tabi ohun kan bẹẹ. Sugbọn Dafidi wipe, “Emi ko mo ohun kan nipa eleyi, nitori emi ko ti I lo o ri. Jẹ ki nlo ohun kan nipa eleyi, nitori emi ko ti I lo o ri. Jẹ ki n lo ohun ti o dami loju, ti mo mọ lati lo” Bẹẹ ni, sa. O mu kanna-kanna rẹ.

67 O si mu ki inu bi Saulu, nitoripe awọn ijọ nkọrin pe, “Saulu ti pa ẹgbẹgbẹrun, Sugbọn Dafidi ti pa ẹgbẹgbẹrun lọna mẹwa”

Nigba naa ni o bẹrẹ si jowu. (Ti awọn kan fi ẹgan sọ wipe “Ekọ 'Jesu nikan' ti atijọ yẹn, ko wulo rara”) Otitọ niyẹn. Kin ni Ọlọrun si ṣe si Saulu? Ọlọrun ran ẹmi buburu sori rẹ lati korira Dafidi, o si korira Dafidi lainidi.

Dafidi ni anfaani lati pa a nigba melokan. O ṣeeṣe fun un, sugbọn o fi silẹ. Dafidi ko sọrọ kan to buru si i. O ṣeeṣe fun un lati ṣe bẹẹ. O lọ, o si ge iṣẹti asọ rẹ loru ọjọ kan, o pada o wipe, “Wo ibi yii!” Ṣe o rii? Bẹẹ ni, sa. O ṣeeṣe fun un lati pa, sugbọn, ko ṣe bẹẹ. O ṣeeṣe fun un lati tu Ijọ rẹ ka, ki o si bẹrẹ ẹgbẹ tirẹ bi o ba fẹ. Sugbọn ko ṣe bẹẹ. O sa fi Saulu silẹ. Jẹ ki Ọlọrun ja ija naa. Bẹẹ ni, sa.

68 Bi o ti tẹsiwaju, ti iṣẹ naa npari lọ, ẹmi eṣu yẹn mu ki Saulu ma lee ri idahun gba lọdọ Ọlọrun mọ. Nigbati Ẹmi Ọlọrun ti fi silẹ. Samuẹli arugbo naa, ẹniti wọn ti kọ silẹ, ẹniti o jẹ ohùn Ọlọrun fun wọn, ẹniti o sọ fun wọn ki wọn to bẹrẹ si ṣe bi awọn eniyan aye.

Kin ni idi ti Ijọ fi fẹ ma a huwa bi ti aye? Kin ni idi ti awọn Pẹntikọsita, Mẹtọdisti, Baptisi ati Piresibiteria ti a ti baptisi pẹlu Ẹmi Mimọ fi fẹ safarawe aye? Kin ni idi ti wọn fi ṣe e? Emi ko mọ. Ko sa yemi. O wipe, “Ko buru lati ta Kaadi. Ṣe bi igbadun itura diẹ ni” Ẹṣẹ ni. Ko yẹ ki o ni nkan wọnyẹn ninu ile rẹ. Wọn wipe, “Ki i ṣe ohun to buru lati mu bia kekere nibẹ yẹn. A mu diẹ ni. Emi ati Iyawo mi mu diẹ ni ọsan yii.” Ki o to mọ ohun to ṣẹlẹ, awọn ọmọ rẹ naa yoo bẹrẹ si mu diẹ. O daju pe bẹẹ ni.

69 Ẹyin Obinrin, ah! Eṣu sa ti gba yin mu. Ohun ti o ṣe niyẹn ni ibẹrẹ, o si ti fi ẹyin arabinrin ṣe afojusun rẹ. Eṣu nṣe iyẹn nitori pe o mọ ohun ti oun le ṣe. O le e tan obinrin jẹ ni igba ẹgbẹrun ki o to tan ọkunrin kan jẹ. Mo mọ pe inu yin ko dun si iyẹn, sugbọn otitọ ni. Bẹẹ lo ri gẹlẹ. Ohun ti o ṣe niyẹn ninu ọgba Edẹni. Efa jẹ olootọ, o si jẹ olododo ni ọkan rẹ; sugbọn a tan an jẹ. “A ko tan Adamu jẹ” A ko tan ọkunrin jẹ, sugbọn a tan obinrin naa jẹ. Nitori naa, eṣu le e tan an jẹ.

Sibẹ, awọn olusọ-aguntan nyan awọn obinrin lati jẹ oniwaasu, wọn si fi wọn sori Ijọ bẹẹ, nigbati Bibeli da iyẹn lẹbi lati Jẹnẹsisi de Ifihan. Iwọ wipe, “O dara, o dara. Awọn obinrin le e waasu daradara bi ti ọkunrin”

70 Gẹgẹbi ẹnikan ṣe bẹrẹ si fi ede sọrọ nigba kan. Emi sa tẹsiwaju ninu iwaasu mi. Nigbati mo de ita, obinrin kan sọ fun ọmọkunrin mi pe, “Mo ni iṣẹ kan lati jẹ ni ọla, nigbati baba rẹ ba wa sibi pẹpẹ iwaasu”.

Ọmọ mi wipe, “Iṣẹ kan, kin ni o nsọ”

Ni alẹ ọjọ naa, nigbati mo fẹ ma a pe awọn eniyan lati wa sibi pẹpẹ fun ironupiwada, obinrin naa tun irun ori rẹ ṣe, o wọ ibọsẹ rẹ daradara, o mura silẹ. O bẹ dide si aarin ijọ, o si bẹrẹ si fo soke, o fede sọrọ o si

sọtẹlẹ. Mo sa a nwaasu lọ ni, mo si pe awọn to fẹ gbagbọ wa sibi pẹpẹ. Emi ko tilẹ bu ọla fun un rara. Ko tọ. Bibeli lodi si ohun ti o ṣe yẹn. O wipe, “Ẹmi awọn wolii a ma tẹriba fun awọn wolii.” Ọlọrun nsọrọ lọwọ nibi pẹpẹ, jẹ ki o sọrọ. Paulu wipe, bi a ba fi ohun kan han fun ẹnikan, jẹ ki o dakẹ titi ti ẹni to nsọrọ yoo fi ṣetan. Otitọ niyẹn.

Nigbati mo de ita, ọpọ eniyan wipe, “Iwọ ti mu Ẹmi Mimọ binu lalẹ yii”

Mo wipe, “Kin ni mo ṣe?”

Wọn wipe, “Nigbati arabinrin yẹn jẹ iṣẹ yẹn, halleluyah”

Mo wipe, “Emi nwaasu, obinrin naa ko ba eto mu”.

Wọn wipe, “Ah, tirẹ nbọ taara lati ori itẹ. Tirẹ wa ni akọtun ju ohun ti iwọ nsọ lọ” Ha!

71 Bayi, iyẹn fihan ọ. O fihan wipe - mo si sọ ọ pẹlu ibọwọ - yala iṣiwin, tabi aibọwọ-fun, tabi ailẹkọ to yẹ, ti ko mọ ohunkohun nipa Ọlọrun. Emi ko sọ iyẹn lati ṣe awada, nitori ibiyi kii ṣe ibi awada. Sugbọn otitọ pọnbele niyẹn. O yẹ ki a mọ wipe Ọlọrun kii ṣe olupilẹṣẹ rudurudu. Alaafia ni Oun. Wọn ko mọ Bibeli. Wọn ko mọ ju ariwo ati fifo soke lọ, ki wọn fi ede sọrọ, ki wọn le wipe, “Mo ni Ẹmi Mimọ, Halleluyah”.

Mo ti wa nibikan ni Afirika, ti mo ri awọn oṣo ti wọn nfede sọrọ (Ẹgbẹrun marun wọn lẹẹkan naa), ti wọn nfo soke sodo, ti ẹjẹ wa ni gbogbo oju wọn, ti wọn nmu ẹjẹ lati inu akoto-agbari-eniyan; ti wọn si npe eṣu, ti wọn nfi ede ajeji sọrọ.

72 Sibẹ, fifi ede sọrọ jẹ ẹbun Ọlọrun kan. Sugbọn iyẹn kọ ni ami to daju pe eniyan ni Ẹmi Mimọ. Mo gbagbọ pe eniyan kan, nigbati Ẹmi Ọlọrun ba mi si i pupọ lee fi ede titun sọrọ. Mo gba iyẹn gbọ. Sugbọn emi ko gbagbọ pe, iyẹn jẹ ami to fihan pe iwọ ni Ẹmi Mimọ. Bẹẹ ni, Sa.

Mo gbagbọ pe, igba miran le wa, ti iwọ ni igbagbọ - ti ẹnikan yoo lọ gbe ọwọ le ọmọ kan to ni aisan jẹjẹrẹ (nibiti aadọta oniwaasu ti gbadura fun un tẹlẹ) a o si wosan nitoripe iya naa ni igbagbọ fun ọmọ yẹn. Ọlọrun ti fi fun un, oun si jẹ ẹya kan ninu ara Kristi. Bẹẹ ni, mo gba iyẹn gbọ. Mo ti ri i ri, ti a ṣe iyẹn, mo si mọ pe otitọ ni. Sugbọn ohun ti o jẹ ni pe, ki a fi ijọ si eto, ki o ba le siṣẹ.

73 Jẹ ki a pari iyoku ẹsẹ yi ki a to lọ.

……Lẹyin ti ẹyin ti gbagbọ, a fi Ẹmi Mimọ ṣe edidi yin.

Edidi - Kin ni edidi kan? Kin ni edidi tumọ si? Ṣaaju, o fihan wipe a ti pari iṣẹ kan. Iṣẹ ti o ti pari ni; Lẹyin naa o tumọ si Ẹniti o ni ohun kan, Lẹyin naa o tumọ si ipamọ, idabobo.

Fun apẹrẹ, mo ti ma a nsiṣẹ fun ile iṣẹ ọkọ oju irin ti Pennsylvania. Mo ti ma a nsiṣẹ pẹlu baba mi ninu ile iṣẹ naa. A ma a nto Ọkọ ayọkẹlẹ sinu apoti akẹru oju irin. A si ma a nko awọn ẹru sinu apoti akẹru ti ọkọ oju irin naa. A o to wọn fini-fini. Sugbọn ki wọn to fi edidi di ọkọ akẹru yẹn, olubẹwo yoo wa, yoo si ti ẹru naa sihin-sọhun, yoo ti i sibi, ti i sọhun. Bi o ba dun pẹrẹ, yoo fagile tito ẹru naa. Wọn yoo wo, yoo si sofo ki wọn to de ibiti o nlọ. Yoo fagile tito ẹru yẹn! Yoo wipe, “Ẹ tu wọn kalẹ. E tun un to lẹẹkan si” Olubẹwo fagile bi wọn ti di ẹru yẹn sinu ọkọ naa.

74 Ẹmi Mimọ ni olubẹwo naa. Yoo mi ọ diẹ, bi iwọ ba si pariwo diẹ. “Ṣe iwọ gba gbogbo ọrọ Ọlọrun gbọ?”

“Emi ko gbagbọ ninu igbagbọ orukọ Jesu yẹn”

“Fagile e” Iwọ ngbọn, o ndun.

“Emi ko gbagbọ ninu iwosan lailoogun, Ko si ohun to jọ bẹẹ.” O si ngbọn sibẹ. Mu un jade kuro.

“Ṣe iwọ gbagbọ pe, Jesu Kristi jẹ ọkan naa.”

'Hun un. Ni ọna kan'

“Iwọ ngbọn sibẹ, o ndun. Lee jade. Ko ti I ṣetan sibẹ” Bẹẹ ni sa.

Arakunrin, nigbati o ba le ṣe Amin si gbogbo Ọrọ naa.

Ṣe iwọ ti gba Ẹmi Mimọ lati igbati o ti gbagbọ? “Amin!” Ṣe ohun gbogbo ti pe patapata? “Amin” Nigba naa, kin ni olubẹwo yoo ṣe? Ati to gbogbo ọrọ finifini, to kun fun ihinrere. Ah, “Gbogbo Ọrọ Ọlọrun ni o dara. Gbogbo rẹ ni o pe. Mo gba gbogbo Ọrọ Ọlọrun gbọ. Amin! Amin! Amin! Ṣe o gbagbo pe Ọlọrun si n wosan? ”Amin.“ Ṣe o gbagbo pe Jesu jẹ ọkan naa lana, loni, ati titi lae? ”Amin.“ Ṣe o gbagbo pe Ẹmi Mimọ jẹ arigbamu loni bii ti atẹyinwa? ”Amin.“ Ṣe iwọ gbagbọ pe Ẹmi kan naa to wa sori Paulu ni o wa sori wa?

”Amin“ Ṣe o gbagbo pe O n ṣe ohun kannaa lori loni bi o ṣe ṣe lori wọn tẹlẹ? ”Amin.“ Àh, áh, àh, o ti nto fini-fini bayi. Ṣe o ri i. O ti nduro bi o ṣe tọ, a ti ṣetan lati ti ilẹkun bayi. O dara.

75 Nigba naa ni Olubẹwo yoo ti ilẹkun. Kin ni yoo tun ṣe? Yoo fi edidi kan si ori rẹ. Yoo mu irin iṣẹ ti o fi nṣe edidi, yoo si fi edidi di i. Ki a ma ri I pe, iwọ ja edidi yẹn. Bi o ba jẹ Boston ni ọkọ yẹn nlọ, ko si ẹniti o le si I lọna - O jẹ ọran ti eniyan yoo lọ si ẹwọn fun bi o ba ṣi edidi yẹn loju ọna - titi ti yoo fi de Boston.

Ọkunrin kan ti o ni aṣẹ lati ṣi I ni o le e ṣi edidi naa. Oun nikan ni. Otitọ niyẹn. Ile iṣẹ irina-oju-irin kan pato ni ó ni iń. Edidi wọn ni. O si jẹ idaniloju wọn wipe, a ti to ọkọ naa tan, o si ti ṣetan, tiwọn si ni. Wọn ko lee fi ami edidi ti ile iṣẹ kan le ori ẹru ile iṣẹ miran.

A nilati fi edidi di ọ, nigbati a ba si ti di ọ …..

76 Nigbati a ba ti fi ihinrere kun inu Kristẹni kan, ti a fi ohun rere Ọlọrun gbogbo kun inu rẹ, pẹlu ọkan ti a ṣipaya, ti o ṣetan lati ṣe iṣẹ, to nifẹ si I ki a fi oun si ipo ti o yẹ, lati ṣe iṣẹ to nifẹ si I ki a fi oun si ipo ti o yẹ, lati ṣe ohunkohun ti Ẹmi Mimọ sọ fun un ki o ṣe, ti o ti rekọja iku si iye, ti a si ti sọ ọ di mimọ kuro ninu gbogbo nkan aye, ti o nrin ninu imọlẹ bi imọlẹ ti ntọ ọ wa, ti o nrin pẹlu imọlẹ, o ti ṣetan. Nigba naa ni Ọlọrun yoo ti ilẹkun mọ aye si ẹyin rẹ, yoo si fi Ẹmi Mimọ ti Ileri ṣe edidi rẹ. Halleluyah!

Titi di igba wo? Titi de ibiti o nlọ. Wọn ko ni gbe e de oju irin ki wọn tun ṣi I wo, lati wo o bi ohun gbogbo ba wa ni ipo rẹ. Ohun gbogbo ni o wa bi o ṣe yẹ, iwọ sa fi silẹ. Olubẹwo ti ṣe ayẹwo rẹ. Titi di igba wo ni a fi edidi di i? Titi di ọjọ irapada rẹ. Bi edidi rẹ ṣe pẹ to niyẹn.

“O dara Arakunrin Branham, igba ti o ba ku nkọ? O sọ wipe o si ni in sibẹ”. O ni in titi lae. Nibo ni iye ti nbẹrẹ? Nibi pẹpẹ ni. Nibẹ, iwọ yoo ri ojiji kekere kan. Ojiji naa niyẹn, ti I ṣe edidi ti Ẹmi Mimọ. Nigba naa, o jẹ ojiji, ti ojiji, bi mo ti sọ ni ijelo. Sugbọn nigbati iwọ ba ku, iwọ yoo ma a kọja lọ ninu awọn ojiji yẹn titi ti iwọ yoo fi de ooru ti o lomi ninu, lati ooru naa, iwọ yoo de isun teere kan, lati isun teere, iwọ yoo de iṣẹlẹru, lati iṣẹlẹru de odo kekere kan, lati odo kekere, yoo di odo nla, lati odo nla, yoo di okun ti ifẹ Ọlọrun. Ẹnikan naa ni iwọ.

77 Wo o. Saulu atijọ naa, ti o ti pada sẹyin, ti ko si lee fi ọwọ kan Ọlọrun, sibẹ ohun ko sọnu. Dajudaju ko sọnu. Wolii ni oun, sugbọn o kuro ninu ifẹ Ọlọrun. (Idi niyẹn ẹyin ara ti mo fi sọ wipe, iwọ ko sọnu) Nitori naa, ranti pe, oun yẹ kuro ninu ifẹ Ọlọrun ni. Ohun kan ni wipe, oun ko gba itọni. (Bayi, boya ko yẹ ki nsọ iyẹn. O dara, Emi sa nba ipejọpọ kan tinu wọn dun sọ̀rọ̀ lalẹ yii) Nitori naa, o lọ sibi Urim ati Tumimu.

O mọ ohun ti Urim ati Tumimu jẹ. O jẹ apata-igba-aya, aṣọ mimọ ti Aroni wọ. Nigba gbogbo ni Ọlọrun ti ma a njẹ alagbara to ju ẹda lọ, ti o ma a nda eniyan lohun pẹlu agbara nla to ju ẹda lọ. Nigba ti wolii kan ba sọtẹlẹ, ti Imọlẹ to ju ti ẹda lọ naa ko si tan sori Urimu Tumimu, isọtẹlẹ naa kuna. Nigbati alala kan ba rọ ala rẹ, ti imọlẹ naa ko si tan sori Urimu Tumimu, bi o ti le dara to loju, to dun gbọ leti, o kuna. Otitọ niyẹn.

78 Emi ko si fẹ mọ bi awọn oye ọmọwe ti iwọ ni ṣe pọ to, ati bi ẹgbẹ ẹlẹsin rẹ ti tobi to, nigbati iwọ ba sọtẹlẹ, tabi waasu, ti ko si ba Ọrọ yii mu, arakunrin iwọ kuna. Ọrọ yii ni Urimu Tumimu. Nigbati iwọ ba sọ wipe, a ko yanwa tẹlẹ ṣaaju ipilẹṣẹ aye, imọlẹ Urimu Thumimu ko ni tan, nitori pe Bibeli sọ pe, a ti yanwa tẹlẹ. Nigbati iwọ ba wipe, a nilati ṣe itẹbọmi ni orukọ Baba, Ọmọ ati Ẹmi Mimọ, imọlẹ yẹn ko ni tan, nitoripe ko si ẹniti a baptisi bẹẹ ninu Bibeli, kiki ni orukọ Jesu Oluwa ni. Ko ni tan na, nitori naa, ohun kan kuna nibi kan.

79 Nitori naa, Urimu Thumimu ko da Saulu lohun, bẹẹ ni ko la ala. O ti jinna si Ọlọrun, to bẹẹ ti ko fi le la ala. Ṣe o mọ ohun ti o ṣe? O wa ajẹ yẹn lọ. O sọ fun un wipe, “Ṣe iwọ le e ṣe iwadi fun mi nipa ẹmi?”

Obinrin naa wipe, “Bẹẹ ni, sugbọn Saulu wipe, ẹnikẹni ti o ba ṣe ibokusọrọ, yoo ku”

Saulu wipe, “Emi yoo daabo bọ ọ” O wọ aṣọ bi i ti iransẹ kan. O wipe “Ba mi pe ẹnikan ti o ti ku wa fun mi (Fetisilẹ si eleyi) ba mi pe Samueli, wolii wa”

Obinrin naa si lọ ṣe iboku sọrọ. Nigbati ti o si ṣe bẹẹ, o dojubolẹ. O wipe mo ri awọn ọlọrun ti wọn njade wa. Wo o, keferi ni. Awọn Ọlọrun meji tabi mẹta gẹgẹbi Baba, Ọmọ, Ẹmi Mimọ. O wipe, “Mo ri awọn ọlọrun ti wọn nji dide”

Saulu wipe, “Sapejuwe rẹ. Kin ni iri rẹ?

O dahun wipe, “Ọkunrin naa tin-in-rin, o si ni agbada kan ni ejika rẹ” Ko ti I yipada rara.

Saulu wipe, “Samuẹli ni. Mu u wa sinu iyara yii. Mu u wa siwaju mi.

Kiyesii, nigbati Samuẹli wa siwaju Saulu. O wipe, “Kin ni idi ti o fi pe mi jade? Nigbati iwọ ti di ọta Ọlọrun. Kiyesi. Ki i ṣe wipe oun si jẹ Samuẹli nikan, sugbọn o ni ẹmi wolii sibẹ. Iwọ wipe, irọ ni. Jẹ ki ẹnikẹni fihan pe

irọ ni. Otitọ ni! Wolii ni oun sibẹ. Nitori o sọtẹlẹ wipe, ”Ogun yoo lọ lodi si ọ lọla, iwọ ati awọn ọmọkunrin rẹ yoo si ku loju ogun. Ni iwoyi alẹ ọla, iwọ yoo wa pẹlu mi“ Ṣe otitọ niyẹn? Wolii ni oun sibẹ!

Iwọ sọ bayi pe, “Sugbọn ajẹ kan ni o ṣe iyẹn”

80 O dara, emi yoo sọ fun ọ igba miran ti ki I ṣe nipa ajẹ. Jesu mu Peteru, Jakọbu ati Johanu lọ sori Oke Iparada nigba kan, Oun si duro lori oke naa. Ọlọrun si nfi Ọmọ Rẹ sipo, gẹgẹbi ohun ti mo nkọ yin lọwọ. Wọn si wo yika, wọn ri Mose ati Elijah. Wọn nṣe ijiroro, wọn nbara sọrọ. Ki iṣe wipe, ikuukuu kan funfun nfo lọ nibẹ sugbọn ọkunrin niwọn. A si ti sin Mose sinu iboji kan ti ẹnikẹni ko mọ fun ẹgbẹrun ọdun. Elijah si ti goke lọ pẹlu kẹkẹ fun ẹẹdẹgbẹta ọdun. Awọn si niyi, ti wọn si wa laaye gẹgẹbi wọn ti le wa laaye to. Wọn duro nibẹ, wọn nba Jesu sọrọ ki o to lọ si Kalfari. Halleluyah! “A fi edidi di wa titi di ọjọ irapada wa”.

81 Emi yoo yara bayi, a o si pari ki akoko to pẹju, a o si gbadura fun awọn alaisan. O ku bi iṣẹju marun. Ẹ jẹ ki a ka ẹsẹ kẹtala.

Ninu ẹniti ẹyin pẹlu, nigbati ẹyin ti gbọ Ọrọ otitọ ni, ihinrere igbala yin….

Ranti bayi, kin ni igbala ti wọn ni? Awọn Kristẹni ara Efesu niyi. Wo o. Ṣe iwọ sakiyesi awọn ara Kọrinti? Paulu nilati ma a sọ fun wọn pe, “Nigbati mo wa saarin yin, ọkan ni isọtẹlẹ ati bẹẹ bẹẹ lọ, ko si le e kọ wọn ni ẹkọ ijinlẹ nitoripe wọn nfẹ orisirisi nkan. Awọn ijọ yii ni ohun kan naa, sugbọn wọn fi si eto. Ko kọ ijọ Kọrinti ni nkan bi eleyi, ko le e kọ wọn. Ijọ kọrinti ko wa ni ètò tó lati kọ wọn. Sugbọn o le kọ ijọ Efesu ni ojulowo ijinlẹ.

Nigbati ẹyin ti gbọ Ọrọ otitọ ni, ihinrere igbala yin, ninu ẹniti nigbati ẹyin ti gbagbọ pẹlu, a fi Ẹmi Mimọ ileri ni ṣe edidi yin.

Eyiti iṣe ẹri ini wa (Ah, majẹ ki n re eyi kọja) fun irapada ohun ini Ọlọrun si iyin Ogo Rẹ.

Ha ha!

82 Kin ni Ẹmi Mimọ? (Emi yoo tete ka iyoku, bi ẹ ba le farada fun mi de ibi yii) Nibo ni a wa lalẹ ijelo Arakunrin Mike? Nibiti inu gbogbo wọn ti dun, ti ohun gbogbo si jẹ alaafia. Ifẹ pipe niyẹn. Ni gbogbo igba ti iwọ ba nwa saye yii, iwọ ndinku diẹ si. Nigba ti o de aye, iwọ ti di ojiji ti ojiji ti ojiji ti awọn ojiji. Gbogbo Ẹmi Mimọ ti iwọ ni ninu rẹ niyẹn. Ifẹ niyẹn. Sugbọn iwọ sa npongbẹ fun ohun kan ni.

Ah, gẹgẹbi awọn to ti di arugbo, bi o ṣe wu mi to ki emi pada si ọmọ ọdun marundogun si ogun ọdun lẹẹkansi. Emi yoo fi ohunkohun dipo rẹ. Ire wo ni yoo si ṣe fun mi? Mo lee jẹ ọmọ ọdun marundogun, sibẹ, ki nku lalẹ yii. Ko si idaniloju. Ki a sọ pe iwọ jẹ ẹni ọdun marundogun lalẹ yi nkọ? Bawo ni iwọ ṣe mọ pe, iya rẹ yoo wa laaye sibẹ nigbati iwọ ba de ile? Bawo ni iwọ ṣe mọ pe iwọ yoo de ile gan? Bawo ni iwọ ṣe mọ wipe iwọ yoo wa laaye lọla, bi iwọ ba jẹ ọmọ ọdun mejila bayi, ti o si ni ilera pipe? Iwọ le ku ninu ijamba ọkọ, ohunkohun ni o le ṣẹlẹ si ọ. Ko si idaniloju. Ko si ohun to daju laye yi. Sugbọn iwọ npongbẹ fun iyẹn. Kin ni gan? O wa loke lọhun, o si jẹ ki o maa pongbẹ fun un.

83 Bayi, iwọ ti wọ inu igbagbọ yii, o si ni Iye ainipẹkun. Bawo lo ṣe ṣẹlẹ? Itọwo ni.

Kin ni owo asansilẹ fun ohunkohun? Bi mo ba wa ba ọ lati ra ọkọ ayọkẹlẹ kan, ti mo beere wipe, “Elo ni ọkọ yẹn”?

Iwọ si sọ fun mi pe, “Arakunrin Branham, ẹgbẹrun mẹta dọla ni ọkọ yii”

“Elo ni asansilẹ rẹ”

“Emi yoo gbe ọkọ naa silẹ, bi o ba san ẹẹdẹgbẹta dọla”

“O dara, ẹẹdẹgbẹta dọla ni yii. Emi yoo mu owo ti o ku wa fun ọ nigbati mo ba ti ri i. Iwọ jẹ ki ọkọ naa wa lọdọ rẹ” Mo si san ẹẹdẹgbẹta dọla. Asansilẹ niyẹn. Ṣe bẹẹ ni?

Iwọ di eyi mu na. O jẹ ibẹrẹ rẹ, asansilẹ ni. Lẹyin ti a ti fi edidi ti Ẹmi ileri naa di ọ.

Eyi ti o jẹ (Kin ni edidi ileri, Ẹmi Mimọ ileri?) Tii ṣe itọwo ti ogun ini wa. Irapada ogun ini.

84 Kin ni? Asansilẹ ni. Arakunrin, ah, ah, ah! Bi o ba jẹ wipe, asansilẹ ni eleyi, kin ni yoo jẹ gan nigbati a ba ri ẹkun rẹ gba? Kin ni yoo jẹ! Bi o ba jẹ itọwo ni eleyi. Ohun ti a ngbadun bayi, ti o nmu inu wa dun bayi. Mo ti ri I ti o sọ arugbo di ewe.

Mo ti ri baba arugbo oniwaasu kan lalẹ ọjọ kan. O jade wa bi eleyi sibi aga iwaasu, mo wipe, “Ṣe baba arugbo yii fẹ waasu ni?”

O wipe, "Ẹ yin Oluwa logo!" Baba arugbo alawọ dudu kan - o wọ kootu oniwaasu nla kan sọrun.

Mo wipe, "Kin lode ti wọn ko fi jẹ ki awọn ti ko darugbo waasu, bawo ni baba arugbo yẹn ṣe le waasu?"

O wipe, "Ẹyin ara, loni, mo ti ngbọ awọn arakunrin to nwaasu lati owurọ nipa Jesu ati ohun ti o ṣe laye. Emi yoo sọ fun yin, ohun ti o ṣe ni Ọrun". O wipe, emi yoo mu iwe kika mi lalẹ yii ninu iwe Jobu7:27 (Job 38:4-7). Ṣaaju ipilẹṣẹ aye, nigbati awọn irawọ owurọ, kọrin papọ ti awọn ọmọ Ọlọrun si kigbe fun ayọ" O wipe, "Ṣe o mọ pe, ohun kan ṣẹlẹ nigba yẹn" O si bẹrẹ si sọ gbogbo ohun to ṣẹlẹ ni ọrun. O mu un pada wa si ipadabọ Jesu nigba keji.

Ni akoko yẹn, Ẹmi Mimọ fun un ni itagiri ni Ẹmi (Bayi, wọn nilati mu baba arugbo naa jade lọ. Oun si jẹ eniyan bi ọdun marun-din-lọgọrun. O jẹ ẹniti o ti tẹ ba pẹlu ogbo, ti o ni ila irun tẹẹrẹ yipo ori rẹ) O jade sibẹ, o si bẹrẹ si waasu. O wipe, "Whoo-peee! Halleluyah! Ogo ni f'Ọlọrun! O bẹrẹ si fo soke sodo bẹyẹn. O wipe, "Ha ẹyin ko ni aye to fun mi nibiyi lati waasu". O si sare kuro lori pẹpẹ iwaasu bẹyẹn. Itọwo nikan si ni iyẹn. Ah!

85 Kin ni Ẹmi Mimọ nṣe? Ah, ibi kan to dara niyi. Jẹ ki nka ẹsẹ kinni ti ori keji. Ṣe mo le e ṣe? Ṣe o dara? Sọ pe "Amin" O dara, ẹsẹ kinni ti ori keji ni kiakia. Fetisilẹ.

Ẹyin ni o si ti sọ di aaye, ẹyin ti o ti ku tẹlẹ ri ninu irekọja ati ẹṣẹ yin.

"Ẹyin ni O ti sọ di aaye. Kin ni eyi tumọ si? "Sọ di aaye" Ti o ti fẹrẹ ẹ ku tan, sugbọn o sọ ọ di aaye, nipasẹ owo asansilẹ. Kin ni yoo jẹ nigbati a ba ni ẹkunrẹrẹ ere naa? Ah! Ko yanilẹnu, nigbati a gba Paulu lọ si ọrun kẹta, o wipe, "Oju ko ti i riri, eti ko tii gbọ ri, bẹẹ ni ko tii wọ ọkan eniyan ri, ohun ti Ọlọrun ni fun awọn ti o fẹ Ẹ" Kin ni iyẹn yoo jẹ? Bi a ba nsọrọ nipa ayọ ti ko ṣee fẹnu sọ to si kun fun ogo! Ah! ah! Hun! Ẹyin ti o ti ku ninu ẹṣẹ ati irekọja ni o ti sọ di aaye papọ, nipa ojiji ti ojiji ti awọn ojiji. Kin ni yoo jẹ, nigbati iwọ ba ti ojiji awọn ojiji di ojiji ojiji, ti o si di ojiji, lẹhin naa ti iwọ di isun omi teere kan, ti isun omi teere si di odo nla, ti odo nla si di omi okun nla.

86 Kin ni yoo si jẹ, nigbati iwọ ba de ile tan ninu irapada, pẹlu agọ ara titun? Iwọ yoo si di ọdọkunrin ati ọdọbinrin - iwọ ko lee ku mọ. Iwọ yoo si wo ile aye, iwọ yoo ro o wipe, "Nigba kan, mo le gbadun girepu ati omi tutu kan, sugbọn nibi yii, emi ko nilo wọn.

Sugbọn lọjọ kan Jesu yoo wa, ara bii ti angẹli yii, tii ṣe ara Ọrọ yẹn ti mo ngbe inu rẹ, ko ni gba inu-ọmọ ti obinrin wa mọ. Ko ni wa nipa ifẹ ibalopọ ti ara mọ. Sugbọn, nitoripe a bi Jesu lai si ifẹ ibalopọ, a o jimi dide laisi ifẹ ẹran ara. Oun yoo si sọrọ lọjọ kan, awọn oku ninu Kristi yoo jinde, ara ti mo gbe inu rẹ ni igba kan yoo jinde sinu ara ologo kan, emi yoo rin, emi yoo sọrọ, emi yoo wa laaye, emi yoo si gbadun. Halleluyah! Emi yoo wa laaye ninu gbogbo awọn iran ti nbọ wa, nipa Jesu Kristi Oluwa. Ohun niyẹn arakunrin. Ihinrere niyẹn.

87 Paulu sa nsọ bi oun ti jẹ (Emi yoo ka iyoku, lẹyin naa a o gbadura fun awọn Alaisan). Eyi ni itọwo naa, titi ti yoo fi gba ini naa, fun iyin ogo Rẹ.

Nitori eyi, emi pẹlu nigbati mo gburo igbagbọ ti mbẹ ninu yin, (Mo gbọ wipe ẹ gba awọn nkan wọnyi gbọ, mo gbọ wipe ẹ gba iyantẹlẹ, iye ainipẹkun, ati igbala gbọ, ati bẹẹbẹẹ lọ) ninu Jesu Oluwa, ati ifẹ yin si gbogbo awọn eniyan mimọ.

Emi ko si simi lati maa dupẹ nitori yin, ati lati maa darukọ yin ninu adura mi;

Pe ki Ọlọrun Jesu Kristi Oluwa wa, Baba Ogo, le fun yin ni Ẹmi, nipa ti ọgbọn ati ti ifihan ninu imọ Rẹ.

"….Ki o sa maa fun yin ni ifihan Rẹ ni gbogbo igba, ki ẹ maa dagba lati oore-ọfẹ de oore-ọfẹ, lati agbara de agbara lati ogo de ogo. Kii ṣe lati ṣubu sẹyin, sugbọn lati ogo de ogo - ki ẹ maa tẹsiwaju. Emi yoo maa gbadura fun yin".

Ki oju ọkan yin lee mọlẹ;

88 Ẹ mọ pe, Bibeli wipe, Ẹyin fọju ẹyin ko si mọ ọ. Sugbọn nibi yii, Paulu wipe, "Emi yoo maa gbadura fun yin pe ki oju ọkan imoye yin lee mọlẹ" Iwọ nloye pẹlu ọkan rẹ. Ohun ti o nsọ niyẹn. Iwọ nwo pẹlu oju rẹ, iwọ si nriran pẹlu ọkan rẹ. O mọ iyẹn. O dara. "Pe ki Ọlọrun ogo" Jẹ ki a ka ẹsẹ ikeji-din-logun:

Ki oju ọkan yin le mọlẹ; ki ẹyin ki o lee mọ ohun ti ireti ipe rẹ jẹ, ati ohun ti ọrọ̀ ogo ini Rẹ ninu awọn eniyan mimọ jẹ.

Ati agbara Rẹ ti o tobi julọ si awa (Wọn sọ pe agbara naa ti lọ? Agbara naa ko tilẹ ti i bẹrẹ) ti o gba gbọ, gẹgẹ bi iṣẹ agbara Rẹ.

(Ẹyin ti o ti gbagbọ ninu iṣẹ agbara nla Rẹ, mo gbadura pe ki Ọlọrun tun da ọpọ agbara Rẹ le yin)

Ẹyiti o siṣẹ ninu Kristi, nigbati o ji I dide kuro ninu oku, ti o si fi joko li ọwọ otun ninu awọn ọrun.

Ga ju gbogbo ijọba ati ọla, ati agbara, ati oye, ati gbogbo orukọ ti a nda, ki iṣe ni aye yii nikan, sugbọn ni eyiti nbọ pẹlu.

Ah a a ah! Rara, o san ki nma bẹrẹ lori iyẹn. A lee fi gbogbo oru yii sọrọ lori rẹ.

Gbogbo orukọ ti a nda, kii ṣe laye yii nikan, sugbọn ni eyiti nbọ pẹlu.

89 Kin ni orukọ ti a fi npe gbogbo eniyan? (Apejọpọ wipe, "Jesu) Gbogbo ọrun ni a npe ni Jesu, Gbogbo ijọ ni a npe ni Jesu, ohun gbogbo ni a pe ni Jesu, nitori oun ni orukọ kanṣoṣo ti Ọlọrun ti i ni ri. A npe e ni Jeofa Jire, Oluwa irubọ wa. Jeofa Rafa, Oluwa ti o wo wa san, Jehofa Manase, Oluwa aṣia wa, oriṣiriṣi apele Jeofa. A npe ni Irawọ Owurọ, a npe ni Baba, a npe ni Ọmọ, a npe ni Ẹmi Mimọ, a npe ni Alfa ati Omega. A npe ni Ibẹrẹ ati Opin, a npe ni Ẹka Naa. Ah, a npe E ni ọpọlọpọ apele, sugbọn o ni orukọ kan.

Ohun ti Matiu nsọ nipa rẹ niyẹn nigbati o wipe, "Lọ si gbogbo aye, ki ẹ ma kọ orilẹ-ede gbogbo, ki ẹ maa ṣe itẹbomi fun wọn ni orukọ (kii ṣe ni awọn orukọ) ni orukọ Baba, Ọmọ ati Ẹmi Mimọ". Baba kii ṣe orukọ, Ọmọ kii ṣe orukọ. Ẹmi Mimọ kii ṣe orukọ. Apele niwọn si orukọ kan. Orukọ apele, Iwa-iṣẹ mẹta ti Ọlọrun kan ni. Kin ni orukọ Rẹ? Angẹli naa wipe, "Iwọ yoo pe orukọ Rẹ ni —(Apejọpọ wipe" Jesu") nitori Oun yoo gba awọn eniyan Rẹ la kuro ninu ẹṣẹ wọn." Idi niyẹn ti gbogbo wọn fi ṣe itẹbọmi ni ọna yẹn ninu Bibeli. Bẹẹ ni Augustine Mimọ ṣe ṣe itẹbọmi fun Ọba Ilẹ Gẹẹsi ni ọgọrun kan abọ ọdun tabi igba ọdun lẹyin iku ati ajinde Jesu Kristi - o ṣe e ni orukọ Jesu Kristi.

90 Ga ju gbogbo ijọba ati ọla ati agbara ati oye, ati gbogbo orukọ ti a nda, kii ṣe ni aye yii nikan, sugbọn ni eyiti nbọ pẹlu.

Ọlọrun si ti fi ohun gbogbo sabẹ ẹsẹ rẹ, o si fi I ṣe ori lori ohun gbogbo fun ijọ.

Eyiti I ṣe ara Rẹ,

Bayii, bi ara mi ba ni agbara lori ohun gbogbo, nigba naa, ohun ti ara mi jẹ ni emi pẹlu jẹ. Ṣe otitọ niyẹn? Ohun ti mo jẹ niyẹn. Ohun ti ẹ mọ mi si niyẹn. Ṣe otitọ niyẹn? Nigba naa, ohun gbogbo ti Ọlọrun jẹ, o da a sinu Kristi, nitori pe oun ni ẹkunrẹrẹ Ọlọrun ni iduro. Ṣe otitọ niyẹn? Ohun gbogbo ti Jesu si jẹ. O da a sinu Ijọ "Awọn ohun ti Emi nṣe wọnyi ni ẹyin yoo ṣe pẹlu. Ani, titobi ju iwọnyi ni ẹyin yoo ṣe, nitori ti Emi nlọ sọdọ Baba"

Eyiti I ṣe ara Rẹ, ẹkun ẹniti o kun ohun gbogbo, ni gbogbo ọna.

91 Ah, mo fẹran iyẹn. Mo fẹran iyẹn pupọ, Mo nka iwe kan lana nipa irinajo mi kan lọ si Afrika lati waasu. Emi ko ka a ri. Ẹni melo ni o ti ka iwe - Wolii to ṣe ibẹwo si Afrika'? Ninu Iwe naa, mo n wo ọmọkunrin ara India kan. Ẹni melo ni o ri aworan yẹn?

Mo gbọ ti ajihinrere kan ti o ti ngbadura fun alaisan fun ọdun marundogun tabi ju bẹẹ lọ wipe, "Emi ko tii ri iṣẹ iyanu kan ri laye mi." Mo ti ri I ti awọn ti o ni ẹfọri tabi inu rirun, ati bẹẹ bẹẹ lọ ni imularada. Sugbọn iṣẹ iyanu, ki a da ẹya ara kan, tabi ohun bẹẹ, ko ti I ṣẹlẹ pẹlu mi"

Mo roo wipe, o yẹ ki ọmọkunrin yẹn wa nibiti iyẹn ti ṣẹlẹ, ki o si ri i. Ọmọkunrin India yẹn ni ẹsẹ kan ti o tobi pupọ ju ekeji lọ. Bi o ba si kiyesi ohun to fi gbe ẹsẹ duro, bata ẹsẹ kan nilati ga to inṣi bi marundogun ki o to le ba ẹsẹ keji dọgba. O si ni irin ni abẹ rẹ. O rin wa sibi ti mo wa. Wọn mu u wa sibẹ. O si ni ọpa itilẹ meji ni abẹ ejika rẹ. O gbe ẹsẹ bata onirin nla rẹ, o si gbe e kalẹ bẹyẹn. Mo wo ẹsẹ rẹ. O tobi pupọ yipo.

92 Awọn eniyan naa jẹ ẹlẹsin Mọmọdu. Ṣe iwọ ranti ni ọjọ Aiku to kọja nigbati mo ka ohun ti awọn iwe iroyin sọ? Mo ni-in nibi yi, iwe iroyin lati Afirika ti wọn fi ranṣẹ simi lati ọwọ Arakunrin Stricker, to jẹ akiri-waasu to pada wa. Apilẹkọ nipa bi Billy Graham ṣe sa fun ipenija lori iwosan nipa agbara Ọlọrun si wa nibẹ, (Otitọ niyẹn) ti o si gba awọn Musulumi laaye lati le e kuro loke okun. Kin ni o ṣẹlẹ? Awọn akiri-waasu nkuro loju papa iwaasu. Kin ni anfaani diduro sibẹ mọ? Wọn ti ṣẹgun wọn.

Mo ni fẹ Billy Graham. Mo ro wipe iranṣẹ Ọlọrun to dara pupọ ni. Sugbọn ohun ti o yẹ ki Billy Graham ti sọ ni wipe, "Ẹ duro na (Bi awọn Baptisti to ti gan wọnyẹn ba gba a laaye lati ṣe e; mo gbagbọ pe oun iba ti ṣe bẹẹ. Mo gbagbọ pe Billy Graham jẹ Iransẹ Ọlọrun) Sugbọn bi oun ba ti sọ wipe, "Ẹ gbagbọ ninu Majẹmu Laelae ẹ si wipe eniyan lasan ni Jesu iṣe. Mo pe yin ni ja si ifọrọwerọ kan"

Emi ki i gba ipenija eṣu, rara sa. Sugbọn nba ti pe e nija wipe, "Jẹ ki emi ati iwọ wa pade. Emi jẹ ọmọwe nipa ẹsin (Billy Graham jẹ omowe-nipa ẹsin Ọlọrun) Jẹ ki n pe ọ nija lori eleyi, jẹ ki nfi ye ọ wipe Jesu ni

Kristi. Bi o ba si jẹ nipa ti iwosan nipa agbara Ọlọrun, emi ko ni ẹbun wọnyẹn, sugbọn a ni awọn arakunrin to ni wọn. Bi o ba fẹ ki a pe awọn arakunrin bẹẹ wa sibi, a ni Oral Roberts ẹnikan bẹẹ - ẹnikan to ni iṣẹ iriju iwaasu nla kan ti o le e ṣe e gidi. Ki o lọ sibẹ, iwọ yoo si ri ohun ti yoo ṣẹlẹ. Sọ fun wọn pe, "Kristẹni kii ṣe ohun ti wọn ro pe o jẹ"

93 Bayi, gbogbo eniyan ni agara da, oun sa fi ẹlẹsin musulumi naa silẹ, o si rin kuro nibẹ. Emi ko gbagbọ pe mo nilati da ipenija eṣu lohun. Emi pẹlu ti tu itọ si loju bẹyẹn ri, ti mo si fi silẹ lọ. Otitọ niyẹn. Sugbọn Billy tilẹ mu ki Musulumi yẹn dabi eweko igbẹ lasan. O yẹ ki o mu Bibeli rẹ, ki o ṣi Aisaya 9:6 ki o wipe, "Ta ni eleyi nsọrọ nipa rẹ? A bi ọmọkunrin kan fun wa, a fi ọmọkunrin kan fun wa? Ta ni ọkunrin naa? Ta ni ibiyi nsọ nipa rẹ? Ta ni wolii yii? Ta ni Mesaya ti yoo wa naa? Fi han mi, ibiti Ọlọrun ti mu eyi ṣẹ nipa Mọmọdu.

"A pa a lara fun irekọja wa, a lu u fun ẹṣẹ wa, ina alaafia wa nbẹ lara Rẹ, nipa ina rẹ a ti mu wa larada. Fi iyẹn han mi ninu Mọmọdu. Bi o ṣe kigbe wipe, "Ọlọrun Mi, Ọlọrun Mi eeṣe ti iwọ fi kọ mi silẹ? Wọn lu ọwọ Mi ati ẹsẹ Mi; ati bẹẹ bẹẹ lọ? Fi han mi nipa iwe ẹsin ti yin". Kinla, oun iba ti bori Musulumi yẹn to bẹẹ ti oun I ba ma mọ ibiti o wa. Otitọ niyẹn.

94 Sugbọn nigba ti iwe yii wa kọ nkan wọn; ti o si mu ki o dun mi niyi. Nigbati Iwe naa wipe, "Bi o tilẹ jẹ wipe Billy Graham tuba, o si sa, bawo ni ẹlẹsin Mọmọdu yẹn ṣe le sọ pe ko si iṣẹ iyanu nipa agbara Ọlọrun nigba ti Ẹni-ọwọ William Branham ni Durban, ni Guusu Afirika, pẹlu awọn iṣẹ iyanu ti ko si ẹni to le e ṣe atako rẹ, to si ṣẹlẹ ni sitẹ-tẹlẹ pẹlu agbara Ọlọrun, ti ẹgbẹrun mẹwa Musulumi si tuuba, ti wọn dojubolẹ ninu isin kanṣoṣo, ti wọn si jọwọ aye wọn fun Jesu Kristi." Otitọ patapata ni. Wọn mọn nipa rẹ. Awọn ẹlẹkọ ipilẹ Bibeli yẹn mọ nipa rẹ. Ma sọ ohun miran fun mi.

Nigba kan ẹnikan tọ Jesu wa, o wipe, "Rabbi (ṣe ẹ mo wipe, Farisi ni) o wipe, "Awa mọ wipe olukọni lati ọdọ Ọlọrun wa ni Iwọ nṣe. Awa mọ iyẹn. Nitori pe ko si eniyan kan lo ṣe nkan ti iwọ nṣe, laiṣe wipe Ọlọrun wa pẹlu Rẹ. O ye wa. A mọ ọn, sugbọn a ko le e jẹwọ rẹ, nitori pe bi awa ba ṣe bẹẹ, wọn yoo le wa kuro ninu ijọ. Wo o, a o sọ ipo wa nu laarin awujọ" Nigba naa ni Jesu sọ fun un pe, o nilati di atunbi.

95 Ni ti ọmọkunrin Musulumi yẹn, nigbati o duro nibẹ. Aworan rẹ niyi. Ẹrọ to nyaworan yẹn ko ni ya irọ. Oun niyẹn ti o duro nibẹ, ti ẹsẹ kan kuru pupọ si ẹsẹ keji (pẹlu inṣi mẹrinla) ti o naro lori bata irin. Mo sọ fun un pe, "Ṣe iwọ le sọ ede gẹẹsi?"

Ogbufọ sọ wipe, "Rara sa. Oun kii sọ Gẹẹsi"

Mo bere nipasẹ ogbufọ pe, "O ti to igbawo ti iwọ ti wa bi eleyi?"

"Lati ọjọ ti a ti bimi"

"Ṣe iwọ lee lo ẹsẹ naa rara?"

"Rara, Sa"

"Ṣe iwọ gbagbọ ninu Jesu Kristi?"

O wipe, "Musulumi ni mi"

Mo wipe, "Ṣe iwọ yoo gba Jesu bi o ba wo ọ san?"

'Emi yoo gba Jesu ni Olugbala bi O ba wo mi san?"

"Bi o ba jẹ ki ẹsẹ yẹn ri bi ekeji iwọ yoo gba A?

"Emi yoo gba A"

96 "Iwọ Ọlọrun kin ni iwọ yoo ṣe?" Ohun ti o kan niyi. Gbogbo ibeere ni o ti dahun. Arakunrin Mike, mo nilati gbọ ohun ti Oluwa yoo ṣe. Mo duro diẹ fun iṣẹju kan lati mọ ohun ti Oluwa yoo sọ. Mo wo yika, mo si ri ọmọkunrin naa ti o nrin lọ lẹgbẹ ogiri kan.

Mo wipe, "Ẹyin Musulumi melo ni yoo gba a gbọ? Ọmọkunrin Musulumi kan niyi. Wo o bi o ti duro bayi. Ẹyin dokita, ṣe ẹ fẹ ṣe ayẹwo rẹ?" Mo mọ ibiti mo duro si. Ko si ẹniti o sọrọ.

Mo wipe, "Rin kọja ni ibiyi, ọmọkunrin" Wọn si mu un. O bẹrẹ si fi gbogbo agbara gbe ẹsẹ yẹn rin. Mo wipe, "O dabi pe, o fi inṣi mejila si mẹrinla kuru si ekeji."

Wọn wipe, "Bẹẹ ni"

Mo wipe, "Sugbọn Jesu Kristi, Ọmọ Ọlọrun lee mu u larada. Ṣe ẹyin Musulumi yoo gba a gbọ ni

Olugbala yin?"

Ẹgbẹẹgbẹrun awọn ọwọ eniyan dudu yẹn si na ọwọ soke bẹẹ. Mo wipe, "Oluwa, akoko ti to. Baba wa Ọrun, bi iwọ ba ti dahun adura mi ri, wa damilohun bayi. Eyi wa fun ogo Rẹ. Mo gbadura pe ki o mu ọmọkunrin yii larada" Mo sa a gbadura fun un bẹyẹn.

Mo wipe "Bọ bata rẹ kuro" O wo oju mi pẹlu iyemeji. Mo tun wipe, "Bọ bata rẹ kuro" O tu u. (Nitori pe mo ti ri iran yẹn, mo mọ ohun ti yoo ṣẹlẹ) O tu bata rẹ kuro, o rin pada sọdọ mi, pẹlu ẹsẹ rẹ mejeeji ti wọn ri bakan naa, bi emi ṣe nrin gẹlẹ. Mo wipe, "Ṣe o fẹ rin kaakiri bayi?"

O bẹrẹ si sọkun, o rin lọ ọtun ati si osi, ko si mọ ohun ti yoo ṣe. O wipe, "Ah,

Allah! Allah!

Mo wipe, "Jesu! Jesu! ni"

O wipe, "Ah, Jesu, Jesu" Lẹyin naa, Jesu! Jesu!"

Mo wipe, "Ṣe ibeere kan wa bi?"

97 Ẹyin melo ni ẹ mọ Jullius Sadsklev? Arakunrin Stadsklev, ti o wa sinu isin nibi. O ṣẹṣẹ lọ si Germany ni. O wipe, "Ẹ duro na, Arakunrin Branham. Ṣe mo le mu onifọto wa ki wọn ya foto rẹ?

Mo wipe, "Ṣe ohun to ba fẹ".

O rin lọ sibẹ. O fi bata rẹ sibẹ, o si ya fọto ọmọkunrin naa. Ẹsẹ mejeji niyẹn ti

wọn duro daradara; ti bata rẹ ati irin ti o fi nrin tẹlẹ si niyẹn.

Mo wipe, ẹyin Musulumi, melo ni yoo kọ Mọmọdu silẹ gẹgẹbi wolii yin, ti yoo si gba Jesu gbọ, pe Ọmọ Ọlọrun ni, ti o si gba A ni Olugbala rẹ?" Ẹgbẹrun mẹwa na ọwọ

soke bẹẹ. Halleluyah!

98 Wọn gbiyanju lati bo otitọ mọlẹ, nitoripe, wọn pe wa ni "gbarayilẹ mimọ" Sibẹsibẹ, Ọlọrun ntẹsiwaju, o nfi ijọ Rẹ sipo. O nṣe iṣẹ lọpọlọpọ ju gbogbo ohun ti a bẹẹ beere tabi ti a nro lọ. Oun jẹ Ọlọrun sibẹ lalẹ yii gẹgẹ bi Oun ti ri nigba kiigba.

Nitori naa, ẹyin ọrẹ, jẹ ki nsọ ohun kan fun yin nisisiyi. Ẹyin eniyan to jẹ olufẹ ọwọn - ẹyin ti ẹ wa nibi bayi, ati awọn ti yoo gbọ fọnran yii, loke okun ati nibi gbogbo ti ẹyin wa - ẹ maṣe bẹru - Ohun gbogbo dara. Ọlọrun Baba wa, ṣaaju ipilẹṣẹ aye ti mọ ohun gbogbo ti yoo ṣẹlẹ - Ohun gbogbo lo nsiṣẹ pọ fun rere. Ṣe iwọ fẹran Rẹ? Pa ọkan rẹ mọ ni titọ.

99 Si ranti wipe, nigbati eemi rẹ ba kuro laye yii, si ẹyin arugbo, ati ẹyin ọdọ, ẹyin iyalọmọ, nigbati ẹ ba ri awọn ọmọ yin - Ọmọ ọwọ kekere to ku ni ọmọ ọjọ mẹjọ yẹn tabi ọjọ marun, ohun yoo jẹ ọdọbinrin to lẹwa nigbati o ba ri i. Baba agba ti o ti hunjọ, to ti kako to fẹrẹ ma riran mọ nigbati o ku yẹn, yoo jẹ arẹwa ọdọkunrin bi ẹni ogun ọdun ninu didun ti ọdọ. Oun yoo si ri bẹẹ titi lae.

Iwọ lee bọ ọ lọwọ. Iwo yoo fi ọwọ ati apa mejeeji fa a mọra, sugbọn ko ni jẹ ọkọ rẹ mọ, yoo jẹ arakunrin. Ah, ah ah! Oun yoo dara pupọ ju ọkọ lọ. O ro wipe o nifẹ rẹ? Bẹẹ ni. Sugbọn ifẹ eniyan niyẹn; duro de ifẹ ti Ọlọrun. Duro de igba ti ifẹ Ọrun yẹn yoo farahan, ki iwọ ri bi o ti ri. Ibi ti a wa yi dabi koto ìdalẹ̀nù si kan ti wọn nfi ina sun lọwọ. Ko dara rara, ko si ohun kan nipa rẹ, ohun kan ṣoṣo ti mo gba ọ nimọran niyi ọrẹ.

100 Nigba ti o ba ṣe diẹ si, ṣe ẹ fẹ ki n wa kọ awọn ori meji ti o ku? Mo nilati sinmi diẹ kin to lọ si Chatanqua. Emi ko le e kọ awọn nkan wọnyi ninu awọn ipolongo ihinrere wọnyẹn. Ẹkọ igbagbọ oniruuru ni o wa. Eyi wa fun Ijọ nikan - Mo ni ẹtọ lati waasu ohunkohun nibi yii ti mo ba fẹ. Ile isin mi niyi.

Bayi, mo gbagbọ pe a ti gba awọn eniyan naa la. Bẹẹ ni. Mo gba a gbọ nitootọ. Melomelo nigba ti iwọ ba nrin, ti o si mọ ibiti iwọ nlọ. Melomelo bi iwọ ba mọ ohun ti iwọ nṣe dipo ki o ma a ta gbọn-gbọn kiri. Jẹ ki a duro ninu imọlẹ naa, ki a si mọ ibiti a nlọ. Otitọ niyẹn. Ki Oluwa wa pẹlu rẹ.

101 Bi ẹnikẹni ninu ẹyin ti o wa nibi ko ba ti I wa ni ipo rẹ. Iwọ le ma ju Iyawo ile lọ. Iwọ sọ wipe, "Arakunrin Branham, emi ko ti I ṣe ohun kan ri laye mi. Emi kii ṣe oniwaasu" O dara, o ṣeeṣe ki Ọlọrun mu ọ wa saye lati tọ ẹbi rẹ, awọn ọmọ rẹ. Lati inu awọn ọmọ yẹn, awọn ọmọ miran yoo tun dide ti oniwaasu kan le e wa ninu wọn ti yoo ran Miliọnu ọkàn lọ sọdọ Kristi. Iwọ nilati wa nibẹ. Iwọ wa nibi fun idi kan. Ṣe iwọ mọ iyẹn.?

Iwọ wipe, "Gbogbo ohun ti emi tii ṣe, ko ju pe mo ro ilẹ oko yii lọ. Mo si sisẹ ni irọlẹ ojoojumọ, emi ko mọ

bi mo ṣe le e tọju awọn ọmọ mi. Mo wo awọn ọmọde naa ti ko si bata lẹsẹ wọn. Mo ti joko ti mo sọkun. Mo ni ẹṣin kan ti emi ati iya fi ma a nlọ sile isin". Ma mikan, arakunrin. Iwọ saa maa nifẹ Kristi. Oun ni èrò kan fun ọ. Iwọ sa a tesiwaju bi o ṣe wa. Sa a tẹsiwaju. Iwọ le ma waasu lẹẹkan ri, sugbọn iwọ le jẹ baba agba fun oniwaasu kan.

102 Njẹ o mọ wipe Ọlọrun ka ohun ti Abrahamu ṣe fun Lefi. O wipe, Lefi san idamẹwa nigba ti o wa ninu Abrahamu, ti Melkisẹdẹki si pade rẹ. Ẹyin melo ni o mọ iyẹn? Ẹ jẹ ki wo o, Abrahamu bi Isaaki, Isaaki bi Jakọbu, Jakọbu si bi Lefi - ti o jẹ baba, baba-a-baba, baba-baba-baba fun Lefi. Ni igbati o wa ni iha baba-a-baba-a-baba rẹ, Bibeli ka a fun Lefi, pe o san idamẹwa fun Melkisedeki. Ah ah ah, arakunrin!

103 Ọkunrin kekere ara Gẹẹsi kan ni iriri iyipada ọkan lọjọ kan ilẹ Gẹẹsi, o wipe, "Inu mi dun! Inu mi dun pupọ!"

Bẹẹ ni, inu mi dun lati mọ pe otitọ niyẹn! Ni ọjọ ologo kan, emi ko mọ ọjọ ti yoo jẹ, sugbọn bi o ba ṣe pe iran kan niyẹn, emi ko sọ pe mo wa nibi. Ranti, ki o fi eleyi sọkan, (pẹlu awọn to ngbọ fọnran iwaasu yii) yala inu iran ni, tabi a gbe mi lọ ninu Ẹmi, emi ko mọ. Sugbọn o jẹ arigbamu bi mo ṣe lee di Arakunrin mi Neville mu bayi. Mo si le e wo awọn eniyan yẹn, mo ba wọn sọrọ. Iyawo mi akọkọ si wa nibẹ. Oun ko si pariwo wipe, "Ọkọ mi" O wipe, "Arakunrin mi ọwọn"

104 Nibẹ, mo ri ọmọbinrin kan ti a jọ jẹ ọrẹ ni ọpọ ọdun sẹyin. O ṣeeṣe ki awọn eniyan rẹ wa nibi bayi - Alice Lewis lati Utika, o jẹ ọmọbinrin Kristẹni kan to dara, to si jolotitọ. O pẹ diẹ ki o to ṣe igbeyawo, nigbati wọn si bi ọmọ wọn akọkọ, o ku nigbati o n bimọ lọwọ. Alice Lewis ni orukọ rẹ. Mo rin lọ si ile igboku-si lati lọ wo oku rẹ. Mo ṣẹṣẹ de lati ibi kan, mo si gbọ wipe o ku. Mo rin lọ sile igboku-si naa, mo wipe, njẹ obinrin kan wa nibi ti o njẹ iya aafin Emmeke. O fẹ ọmọkunrin Kristẹni kan to dara, oun si jẹ ọmọbinrin Kristẹni daradara kan.

Mo ti jade lọ pẹlu ọmọbinrin yẹn ni orisirisi ibikan. Awa mejeji si jẹ ọmọde bi ọdun mejidinlogun ati mọkandinlogun. Nibi gbogbo ti a lọ. Kristẹni to dara ni. Emi ko mọ ohunkohun nipa rẹ bi ko ṣe iwa Kristẹn tootọ. Emi si jẹ ẹlẹṣẹ nigba naa; sugbọn mo ma a nka kiri pẹlu rẹ. Ọkọ rẹ si jẹ ojulowo Kristẹni ti a tunbi, ọkunrin gidi ni. Mo si gbọ pe o ti ku, mo ri I ninu iwe iroyin, mo lọ sile naa lati lọ wo o ni ile igboku-si ti coots. Mo wipe ṣe iya aafin Emmerke wa nibi?

O dahun wipe, "Billy, o wa ninu iyara yẹn".

Mo wọle lọ, mo si duro ti posi rẹ. Mo ro o wipe, "Alice, emi ti wa ni oriṣiriṣi ibikan pẹlu rẹ, ni ahoro to dudu julọ, ni oju popo lalẹ. Iwọ ati emi ti jọ rin lọ si eti odo. Nigbati wọn ma a nni ọkọ oju omi kekere ti wọn fi nṣe ohun iworan yẹn, a o joko sinu rẹ, a o si feti silẹ si awọn bibi omi to nṣere. Ni gbogbo oju titi. Obinrin rere ni iwọ jẹ! Mo dupẹ lọwọ Ọlọrun fun igbe aye rẹ. Ma a sinmi lọ, arabinrin mi ọwọn, sinmi ninu alaafia Ọlọrun.

105 Lalẹ ijelo ninu Iran naa, mo ri I to sare wa ba mi. O wipe, "Arakunrin mi Olubukun" o si fi apa rẹ mejeji wa mi mọra. Ah, arakunrin, arabinrin, iriri yẹn ti yi mi pada. Emi ko le e jẹ ẹnikan naa mọ. O jẹ arigbamu. O jẹ okodoro bi mo ṣe nwo yin bayi, bẹẹ ni o ṣe daju to. Nitori naa, ko si ibẹru.

Mo le e ku ki ilẹ alẹ yi to mọ. Mo fẹ tọ ọmọ mi ọkunrin kekere to wa nibẹ yẹn dagba, Josẹfu. Mo fẹ ri ninu aga iwaasu. Nigbati mo ba lee gbe Bibeli yii, nigbati mo ba ri Josefu to nwaasu gẹgẹbi ọdọkunrin ti a kun fun Ẹmi Mimọ, pẹlu amin ororo Ẹmi Ọlọrun lori rẹ. Mo si gbagbọ pe, oun yoo jẹ wolii. Nigbati mo ri I ni ọdun mẹfa ki a to bi i, ṣe ẹ ranti pe mo sọ nipa bibọ rẹ. Ranti nigbati mo pe e nibi pẹpẹ; lati mọ ohun ti mo nsọ, ti mo nya awọn ọmọ ọwọ si mimọ, mo wipe, "Josẹfu wolii ni iwọ iṣe"

106 Ni ijelo nigbati o duro ninu agbala ile, o wa sọdọ mi, o wipe, "Baba mi, ṣe Jesu ni ọwọ bii tirẹ?"

Mo dahun pe, "Bẹẹ ni, ọmọ mi. Kin ni o de?"

O wipe, "Emi joko sinu kẹkẹ mi, mo nreti sera lati de (Iyẹn ni ẹgbọn rẹ obinrin kekere) lati ile iwe" O joko sibẹ. Emi ko gba a laye lati lọ si oju titi, o si jojo bi eleyi. O wipe, "Mo wo oke, mo si ri ọwọ kan bi i ti ọwọ rẹ, pẹlu apa aṣọ funfun ti o wa lori mi. O si lọ soke. Ṣe ọwọ Jesu ni o lọ soke yẹn?" Mo wo iya rẹ, iya rẹ wo mi. A lọ si ọdọ iya-aafin Wood (Ibikibi ti obinrin naa le wa, o joko ninu isin yii) A jọ beere ibeere lọwọ rẹ, siwa-sẹyin, siwa-sẹyin. Iran kan ni. O rii. Bi mo ba lee ri igba ti Josefu ọmọ kekere yii yoo dagba si. Mo lero pe mo lee rii ki o gbeyawo, bi Jesu ko ba tii de.

107 Emi si ti di arugbo, awọn irun funfun ni o gba gbogbo ọrun mi. Mo fẹ jere miliọnu meji tabi mẹta ọkan si fun Kristi bi o ba ṣeeṣe. O jẹ ipinnu mi lati waasu ihinrere de gbogbo igun aye ja. Bẹẹ ni sa. Nitorina Ọlọrun, ran mi lọwọ, ki nlee ṣe. Bi mo ba lee ri ki igba yẹn de, arakunrin Mike…

Mo lee ri igba ti Mama (Meda ni mo ma a npee, olufẹ mi) a ti n di arugbo. Wo irun rẹ to ndi funfun, wo, o ti nsa, ti a nkọja lọ.

Mo dupẹ lọwọ Ọlọrun fun Rebeka. Olukọ to n kọ ọ ni ohun elo orin sọ fun mi lalẹ ijelo pe, “Bi o ba tẹsiwaju bi o ṣe nlọ yii, o ṣoro lati mọ ibi ti yoo de” Ṣe o rii, o ntẹsiwaju nipa ohun elo orin. Mo fẹ ri Sera lori duuru, ati Becky lori piano. Mo fẹ Josẹfu ninu aga iwaasu.

108 Nigbati mo ba le ri iyẹn, ti emi ati mama lee ta gbọn-gbọn wọle, ti mo nfi ọpa rin lalẹ ọjọ kan, ti mo lee wọ ile isin, ti mo ri ọmọkunrin mi ti o kun fun Ẹmi Mimọ, to nwaasu ihinrere yii kan naa, mo fẹ gbe Bibeli atijọ yii, ki n wipe, “Ọmọ mi, ohun niyi, tirẹ ni. Iwọ duro pẹlu rẹ, maṣe gbabọde lori ọrọ kan ninu rẹ. Iwọ duro pẹlu rẹ, olufẹ. Emi ko fẹ mọ ẹniti o lodi si ọ, Ọlọrun yoo wa pẹlu rẹ. Iwọ waasu gbogbo ọrọ naa bi a ṣe kọ ọ gẹlẹ si nu rẹ. Baba rẹ yoo si ri ọ nikọja odo” O wu mi ki n gba iyawo mi mu lọwọ mi, ki a si re Jọdani kọja sile.

Titi di igba naa, Ọlọrun jẹ ki n fi otitọ duro soju isẹ iwaasu. Ohun ti iba a na mi, ohun ti mo ṣe, tabi iyẹn tabi omiran, jẹ ki nduro ni otitọ si ọ, ati si ọrọ Ọlọrun alaaye, pe, nigbati ọjọ naa ba de, ti mo kọja sọhun, ki nle wo nibẹ ki n wipe, “Iwọ ni yẹn” Ah, iwọ ọrẹ mi ọwọn arakunrin mi ọwọn arabinrin mi ọwọn.

109 Iwọ ọdọ oniwaasu, lọ sori papa iṣẹ, duro sinu ihamọra ogun. Gbogbo ẹyin ọdọ oniwaasu ati awọn bẹẹ, ma ṣe joko lasan. Ẹ ma kan duro laiṣe ohunkohun. Ẹ jade lọ ki ẹ jere ọkan kan. Ṣe ohun kan! Ẹ gbera, ẹ maa siṣẹ. Má duro, iwọ ọdọ oniwaasu, jade lọ sibẹ. Ki Ọlọrun bukun ọkan rẹ.

O ran mi leti akoko ti mo wa ni ọjọ ori yẹn, tabi ti mo kere si I diẹ lọjọ ori. Mo jẹ ẹni ogun ọdun ati diẹ nigba ti mo fi ipilẹ ile ijọsin yẹn lelẹ. Mo ranti pe mo ma nwọ aṣọ awọleke kan ti o ni awọ buluu ati Sokoto funfun, mo si duro nibẹ, mo fi ipilẹ ile yi lelẹ ni nkan bi ọdun mọkanlelọgbọn sẹyin. Ṣe ẹ ri bi mo ti to - mo jẹ ọmọkunrin. Mo na duro nibẹ; mo si fi okuta ipilẹ igun ile yẹn lelẹ. Emi ko ni gbagbọde lori ọrọ kan lati igba naa. Mo ti pa a mọ gẹlẹ bi mo ti fi ipilẹ yẹn lelẹ. Ẹri mi si wa labẹ igun ile yẹn nibiti mo ti kọ ọ si iwe ti a ko tẹ nkan si ninu Bibeli mi, mo si ya a jade, mo fi sabẹ okuta ipilẹ igun ile yẹn. O si wa nibẹ sibẹ. Jẹ ki a si kọ ọ soju Iwe Ọrọ Ọlọrun ainipẹkun ni ọrun. Jẹ ki n duro ni otitọ de opin.

110 Jẹ ki a tẹriba fun iṣẹju kan fun adura. Ni ipari lalẹ yii, ni pipari, ori Kan ninu Iwe naa, ti a ko si ṣe e tan gidi. O yẹ ki a kọ́ awọn ori ti o ku, nibiti o ti fi Ijọ si ipo rẹ. Emi yoo kọ yin nigbamiran bi o ba wu Ọlọrun. Mo nilati ni isinmi diẹ bayi ki nto lọ si Chatanqua, si ipade nla miran. Lẹyin naa, emi yoo rekọja lọ si Oklahoma lati ibẹ.

Ìwàásù lati ẹnu
William Marrion Branham
"... Ati ni ọjọ́ ohùn angẹli keje ..." Ifihan 10:7

www.messagehub.info